Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras
São Francisco do Conde (BA) | vol. 5, nº Especial I | p. 32-60 | jan./ jun.2025.

# Àgbéyẹ̀wò Oríṣiríṣi Ijó nínú Ìṣeré Orin Kete àti Orin Agbè

# Uma visão geral das várias danças em apresentações musicais de Kete e Agbe

**Luqman Abísọ́lá KÍARÍBẸ̀Ẹ́ Ph.D.** *
ORCID iD https://orcid.org/0000-0001-9894-8251
**Philip Adédọ̀tun ÒGÚNDÈJÌ Ph.D., FNAL** **
ORCID iD https://orcid.org/0009-0008-2730-5206

**ÀṢAMỌ̀**
Ìjó jíjó jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú oríṣiríṣi eré tí àwọn òṣèré ewì alohùn Yorùbá máa ń ṣe lásìkò ìṣeré wọn. Ìbéèrè tí ó jẹ wá lógún nínú àtúpalẹ̀ lámèétọ́ inú àpilẹ̀kọ yìí ni pé irú àwọn ijó wo ni ó wà nínú ìṣeré orin kete àti orin agbè, kí sì ni àrokò tí àwón eléré fi wọn pa? Nínú àgbéyẹ̀wò wa yìí a gbìyànjú láti ṣe ọ̀ríkínniwín àlàyé nípa àrokò tí àwọn òṣèré fi ijó pa nínú ìṣseré orin kete àti orin agbè tí a gbà láti oko ìwádìí. Tíọ́rì ìlò-àmì nínú ewì (*semiotics of poetry*), ti Michael Riffaterre (1978) àti tíọ́rì ìṣeré (*performance theory*), ti Richard Schechner (2004) ni a múlò fún ìtúpalẹ̀ détà wa. Láti Igbó-Ọrà, ní Ìbàràpá, Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́, ni a ti gba détà lórí orin kete, a sì gba détà lórí orin agbè láti Igbó-Ọrà kan náà pẹ̀lú Ilùà àti Ìmia ní Òkè-Ògùn, Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́. Ìlànà agbàròkọ alálàyé àti ti àfiwéra ní a gùn lé láti ṣe àtúpalẹ̀ àwọn détà náà. Ìwádìí wa fi hàn pé lára àwọn ijó tó gbajúmọ̀, èyí tí ó máa ń jéyọ nínú àti orin kete, àti orin agbè ni ìlù/ agbè jíjá, ìdọ̀bálẹ̀/ ìyíkàá, fífi-èjìká-jó, olóbìírípobírí/ bírípo pẹ̀lú ijó àti ilù/ agbè lílù papọ̀ lẹ́ẹ̀kan náà. Ijó yíyatan-pípatandé nìkan ni ìwádìí wa fi hàn pé ó máa ń jéyọ nínú orin kete ṣùgbọ́n tí kì í jẹyọ nínú orin agbè. Àwọn ijó tó máa ń jẹyọ nínú orin agbè ṣùgbọ́n tí kì í jẹyọ nínú orin kete sì ni fiwájú-jó-fẹ̀yìn-jó, yọpáyọṣẹ̀/ ẹlẹ́yọ-ẹ̀yọ, fò-lálá àti mẹ́taméta-ẹ̀là/ là-á-mẹ́ta. Àrokò ajẹmẹ́sìn òrìṣà Alárá-Igbó àti ìmọ̀-ọ́n-ṣe nínú ijó jíjó ni àrokò tí ijó pa nínú orin kete, ṣùgbọ́n àrokò ajẹmọ́-ìbágbépọ̀-láwùjọ àti ìmọ̀-ọ́n-ṣe nínú ijó papọ̀ mọ́ àfihàn agbára ni wọ́n fi ijó agbè pa nínú orin agbè. Àrokò ìṣewẹ́kú pẹ̀lú ìwọ́hùn orin náà jẹyọ nínú ìṣeré orin méjèèjì.

**KÓKÓ Ọ̀RỌ̀**
Àrokò, Ìṣeré, Ijó, Orin Kete, Orin Agbè, Alárá-Igbó.

**RESUMO**
A dança é uma das principais formas de dança que os poetas líricos iorubás realizam durante suas apresentações. A questão que nos interessa na análise deste artigo é quais tipos de danças são incluídos na performance de kete e agbê, e qual é a narrativa para a qual os artistas as utilizam? Nesta revisão, tentamos fornecer uma explicação abrangente da narrativa que os artistas usam para dançar na performance de kete e agbê que obtivemos da pesquisa. A semiótica da teoria da poesia, de Michael Riffaterre (1978), e a teoria da performance, de Richard Schechner (2004), foram usadas para nossa análise de dados. Dados sobre a música kete foram coletados em Igbó-Òra, em Ibarapá, estado de Oyo, e dados sobre a música agbé foram coletados no mesmo Igbó-Òra com Ilua e Ìmia em Òke-Ógùn, estado de Oyo. Métodos de análise descritiva e comparativa foram usados

* College of Humanities and Culture, Ọ̀ṣun State University, Òṣogbo, Nigeria, E-mail: luqman.kiaribee@uniosun.edu.ng
** Department of Linguistics and African Language, Faculty of Arts, University of Ìbàdàn, Ìbàdàn, E-mail: pa.ogundeji@mail.ui.edu.ng; dotogundeji@gmail.com

para analisar os dados. Nossa pesquisa mostrou que entre as danças populares que ocorrem tanto na música kete quanto na música agbé estão ìlû/abgé jija, ìdóbále/ìíkáá, fifi-éjúká-jo, olibiípobírí/birípo com dança e ilû/abgé lílu juntos. Nossa pesquisa mostrou que apenas a dança yiyatan-pípatandé ocorre na música kete, mas não na música agbé. As danças que são frequentemente encontradas na música abade, mas não na música kete, incluem fiwaku-jo-f'yin-jo, yopáyósọ/peẹ̀yó-ẹ̀yó, fó-lálá e metaméta-ẹ̀la/lá-á-méta. O tema da adoração à divindade igbo e o conhecimento da dança são os temas que a dança transmite na música kete, mas o tema da conexão social e o conhecimento da dança, juntamente com a demonstração de poder, são transmitidos na música abbe. O tema da morte e o som da canção são evidentes em ambas as apresentações musicais.

**PALAVRAS-CHAVE**
Contação De Histórias, Drama, Dança, Canto Kete, Canto Agbé, Alárá-Igbó.

## Ìfáárà

Ọ̀kan nínú àwọn orin àdáyébá Yorùbá tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn kò mọ̀ nítorí kì í ṣe káàkiri ilẹ̀ Yorùbá ni wọ́n ti ń kọ wọ́n àti pé kò tí ì sí iṣẹ́ akadá tó nǹkan nípa wọn ni orin agbè àti orin kete. Orin agbè yìí ni Ògúndèjì (1979), Àlàbá (1985) àti Kíaríbẹ̀ẹ́ (2023) gbà pé a tún ń pè ní ṣàkàrà. Ṣàkárá tí a pe orin yìí fi pípè jọ ṣákàrà tí àwọn olórin bí i Àbíbù Olùwá, Yusuf Ọlátúnjí (Bàbá Légbàá), Sàlámì Àlàbí Balógun (Lefty), S. Àká, Baba Wàídì, Òsénì Èjìrẹ́, Lìgálí Mùkàíbà àti Sàká Ọláígbadé kọ ní ìgbà ayé wọn. Lára ohun èlò orin tó gbajúmọ̀, tí a máa ń lò sí orin ṣákàrà ni gòjé, àgídìgbo, gángan àti igbá (wo Òjó, 1978, Adélékè, KND) àti ìlù ṣákàrà tí a fi sọ orin náà ní orúkọ. Ọrùn isà/ ìkòkò tí a se awọ sí ojú rẹ̀, tí a sì ń fi igi tẹ́ẹ́rẹ́ kan lù ni ṣákàrà. Èyí yàtọ̀ sí ṣàkàrá tí ó jẹ́ pé agbè tí a sín ọmọ ìdò tàbí èso mìíràn tó le koko mọ́ lára ni. Àwọn mìíràn a máa kó àwọn èso wọ̀nyí sínú agbè dípò kí wọ́n sín in sí ara agbè. Agbè yìí kan náà ni à ń pè ní akerègbè, kèrègbè, akèǹgbè tàbí kèǹgbè.

A ó ṣe àkíyèsí láti inu àlàyé wa yìí pé orúkọ ọ̀kan nínú àwọn ohun èlò orin méjèèjì wọ̀nyí ni a fi sọ wọ́n lórúkọ, bí a ti máa ń ṣe fún púpọ̀ orin àlùjó Yorùbá. Bí a bá tún wò ó dáradára, ọ̀rọ̀ kan tí ìrísí rẹ̀ tún súnmọ́ àwọn ọ̀rọ̀ méjèèjì wọ̀nyí nínú àṣà orin àlùjó Yorùbá kíkọ ni ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀. Yàtọ̀ sí ohùn orí àwọn ọ̀rọ̀ méjèèjì wọ̀nyí, fáwẹ́lì /ẹ/ àti /a/ nìkan ni wọ́n tún fi yàtọ̀ síra. Bí a bá wo àwọn ohun èlò orin náà gan-an, a ó rí i pé ohun èlò orin aláwọ (ìlù) ni ṣákàrà nígbà tí ṣàkàrà àti ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ jẹ́ ohun èlò orin aṣàmúlò agbè. Agbè tí a sín owó ẹyọ mọ́ lára ni ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ ní tirẹ̀. Ohùn rẹ̀ sì máa ń dẹ̀ dáradára ju ti ṣàkàrá lọ. A lè rí ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan nínú ọ̀wọ́ ìlù dùndún. Èyí ló fa bí a ṣe jọ máa ń lu àwọn méjèèjì papọ̀ nínú orin àlùjó kan tí a pè ní dùndún-ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ (tàbí dùndún àti ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀), àwọn aláro náà máa ń lu ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀. Ẹ̀wẹ̀, kò sí ìlù aláwọ kankan tí a máa ń lù sí orin ṣàkàrá. Àgídìgbo àti agogo nìkan ni Ògúndèjì (1979), Àlàbá (1985) àti Kíaríbẹ̀ẹ́ (2023) ṣe ní àlàyé pé àwọn alágbè kan máa ń lù pẹ̀lú agbè nínú ìṣeré orin àlùjó wọn. Ó yẹ kí á tọ́ka sí i wí pé, bí Yorùbá ṣe máa ń pe ṣàkàrá ní agbè ni wọ́n máa ń pe ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ náà ní agbè. Ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ lílù yìí sì ló wọ́pọ̀ káàkiri ilẹ̀ Yorùbá ju ṣkàrá lọ. Àárín àwọn Yorùbá Ọ̀yọ́ nìkan ni ṣàkàrá ti wọ́pọ̀ ní àtijọ́. Ìlò rẹ̀ kò sì fi bẹ́ẹ̀ wọ́pọ̀ ní ayé òde òní.

Kíaríbẹ̀ẹ́ (2022b & 2023) ti ṣe ọ̀rínkíniwín àlàyé nípa bí orin kete ṣe jẹ́ orin òrìṣà Alárá-Igbó àti àwọn òrìṣà mìíràn tí ó jẹ mọ́ ọ̀rọ̀ ọmọ bíbí àti ìtọ́jú ọmọ. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe fi ohun èlò orin sọ àwọn orin bíi ṣàkàrá, ṣákàrà àti dùndún-ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ lórúkọ náà ni a fi kete tí a fi se ìlù orin kete sọ ọ́ lórúkọ. Ohun èlò ìpọnmi sínú ilé ni kete. Òun náà sì ni a tún ń pè ní koto (Kíaríbẹ̀ẹ́, 2022a àti 2023). Nígbà tí àgbẹ̀ bá gbin agbè, ó ṣe pàtàkì kí ọrùn agbè gùn dáradára, kí ó sì tóbi ní ìsàlẹ̀. Ó máa ń ṣòro láti rí agbè tí ọrùn rẹ̀ yọ dáradára bẹ́ẹ̀ nínú ọ̀gọ̀rọ̀ agbè tó bá so nínú oko. Nígbà tí a bá rí agbè tí ọrùn rẹ̀ yọ dáradára bẹ́ẹ̀, irúfẹ́ agbè báyìí ni àwọn àgbẹ̀ fi máa ń dá kèrègbè/ agbè tí a fi ń sín ṣàkàrá àti àwọn tí a fi ń dá ẹmu.

Agbè tí ọrùn rẹ̀ kò bá yọ dáradára, tí ó sì kúrú púpọ̀ ni a máa fi ń dá kete/ koto. Kete/ koto yìí ni a fi máa ń pọn omi jùlọ láyé àtijọ. Koto/ kete jẹ́ agbè tí a ti rẹ́ ọrùn rẹ̀ kúrò, tí ó sì ṣíjú sílẹ̀ ju agbè tí ó ní ọrùn lọ. Ó hàn gbangba báyìí pé láti ara akèrèǹgbè kan náà ni a ti ń ṣe ohun èlò orin agbè/ṣàkàrá àti ti orin kete.

Ògúndèjì (1979) jẹ́ kí á mọ̀ pé eré orin agbè kò fi bẹ́ẹ̀ wọ́pọ̀ mọ́ lóde òní. Ó fi kún àlàyé rẹ̀ pé orin náà jẹ́ èyí tí àwọn ènìyàn Ìmia ní Ìṣẹmi-Ilé máa ń kọ. Nínú àlàyé Ògúndèjì, ìlú Ìlọrin ni àwọn babańlá àwọn ènìyàn Ìmia ti kọ́ nípa eré agbè. Àlàbá (1985) náà kín ọ̀rọ̀ yìí lẹ́yìn pé àwọn ènìyàn Ìlọrin máa ń ṣe eré agbè àti pé Àfọ̀njá ni ó mú àṣà yìí wọ Ìlọrin láti Ọ̀yọ́. Orin kan tí ó tún fi orúkọ jọ orin agbè ní ààrín àwọn Fúlàní Ìlọrin ni orin kèǹgbè. Orin ọba ìlú Ìlọrin ni orin yìí, àwọn obìnrin nìkan ni ó máa ń kọ ọ́, wọ́n sì tún máa ń fi sin ọmọ lọ sí ilé ọkọ láàárín àwọn Fúlàní Ìlọrin. Èyí yàtọ̀ sí orin agbè tó jẹ́ pé orin ogun ni ní ìpìlẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀ (Àlàbá, 1985). Kíaríbẹ̀ẹ́ (2023) náà ṣe àlàyé ní ìbámu pẹ̀lú èrò Àlàbá yìí pé àwọn ọba àti àwọn jagunjagun Ọ̀yọ́ ni wọ́n máa ń kọ orin agbè fún lójú ogun láyé àtijọ́. Wọ́n sì tún máa ń lò ó láti fi dá wọn lára yá ní àkókò ayẹyẹ kan tàbí òmíràn nígbà tí kò bá sí ogun. Ọ̀pádọ̀tun (2002) tilẹ̀ sọ pé Aláàfin Ìtíolú ni ó dá orin yìí sílẹ̀ ṣùgbọ́n Àlàbá (1985) sọ pé kò sí àrídájú ẹni tí ó dá orin náà sílẹ̀ láàrin Aláàfin Ṣàngó, tí a tún pè ní Babáyẹmi Ìtíolú àti Gbọ̀nńkáà tó jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú àwọn olóyè ogun rẹ̀. Síbẹ̀, Àlàbá kò ṣàì fidí rẹ̀ múlẹ̀ pé ní àsìkò tí Ṣàngó jẹ Aláàfin Ọ̀yọ́ ni orin náà bẹ̀rẹ̀. Orin tí ó fi máa ń ṣe kóríyá lójú ogun ni (Ọ̀pádọ̀tun, 2002). Ìwádìí Kíaríbẹ̀ẹ́ (2023) jẹ́ kí á mọ̀ pé orin agbè ṣì wà lóde òní. Àwọn ènìyàn ilé Gbọ̀nńkáà ní Igbó-Ọrà, àwọn ọmọ Ìmià àti àwọn ènìyàn ìlú Ilùà ní Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́ sì ń kọ orin náà.

Owólabí (1974) fi orin kete hàn gẹ́gẹ́ bí orin tí a fi ṣe ayẹyẹ ìkíni-kú-àbọ̀ fún àwọn ọdẹ tó darí dé láti ìrìn-àjò àko nínú ìwé ìtà àròsọ rẹ̀ *Orí Adé Kìí Sùnta*. Àlàbá (1985) fi orin kete wé orin agbè gẹ́gẹ́ bí orin ayẹyẹ. Gẹ́gẹ́ bí orin ayẹyẹ ni Ògúndèjì 1979 náà sì fi orin agbè hàn bí orin ayẹyẹ. Lóòtọ́ ni Ọ̀pádọ̀tun (2002) jẹ́ kí á mọ̀ pé orin ayẹyẹ ni orin kete,ṣùgbọ́n Kíaríbẹ̀ẹ́ (2023) ni ó jẹ́ kí á mọ̀ pé orin ẹ̀sìn Alárá-Igbó àti àwọn òrìṣà mìíràn tí wọ́n ní í ṣe pẹ̀lú ọ̀rọ̀ ọmọ bíbí náà tún ni orin yìí. Òun náà jẹ́ kí á mọ̀ pé a tún máa ń kọ orin kete ní ibi ayẹyẹ, àti pé ibi ayẹyẹ ni a tilẹ̀ ti kọ́kọ́ kó orin náà jáde ní gbangba. Ó ṣe àlàyé pé kọ̀rọ̀ ni a ti kọ́kọ́ máa ń lò ó fún ìsìn òrìṣà Alárá-Igbó láti bẹ̀bẹ̀ fún ọmọ. Ohun tí èyí ń tọ́ka sí ni pé yàtọ̀ sí pé orin kete àti orin agbè jẹ́ orin tí a ṣe ohun èlò wọn láti ara ohun kan náà, tí a si sọ wọ́n ní orúkọ ohun èlò tí a fi ṣe wọ́n yìí, àwọn orin méjèèjì tún jùmọ̀ jọ jẹ mọ́ ayẹyẹ ni. Orin kete nìkan ní ó dá jẹ mọ́ ẹ̀sìn tí orin agbè náà sì dá jẹ́ mọ́ ogun, pàápàá ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ rẹ̀.

## Ìhun-àgbékalẹ̀ ìṣeré orin kete àti orin agbè

Ọ̀nà mẹ́ta ni Ògúndèjì (1979) sọ pé ìhun-àgbékalẹ̀ ìṣeré orin agbè pín sí. Àwọn àgbékalẹ̀ eré náà ni ìbà, ìfira-ẹni-hàn, àti ìdágbére. A wòye wí pé àṣìṣe ni ọ̀nà mẹ́ta yìí jẹ́ mẹ́rin gan-an ni bí a bá wonú àlàyé Ògúndèjì dáradára. Eré gan-an-gan yẹ ki ó wáyé lẹ́yìn ìfira-ẹni-hàn. Bí èyí bá rí bẹ́ẹ̀ ìhun ìṣere mẹ́rẹ̀ẹ̀rin ní ṣísẹ̀ntẹ̀lé yóò wá jẹ́ ìbà, ìfira-ẹni-hàn, eré àti ìdágbére. Àlàbá (1985) ní tirẹ̀ ṣe àlàyé pé àwọn ọ̀nà tí a le pín ìhun-àgbékalẹ̀ ìṣeré orin agbè sí ni ìbẹ̀rẹ̀-eré (overture), ìdánilárayá àti ìpèdè ìkọ́nilẹ́kọ̀ọ́ (entertainment and didatic utterances), ìpèdè ìdágbére àti ìpèdè mìíràn (valedictory and other sayings). Àlàbá ṣe àtúnpín ìbẹ̀rẹ̀-eré (overture) sí ìbà (homage), ìwúre ìbẹ̀rẹ̀ (opening benediction) àti ìfira-ẹni-hàn-ìbẹ̀rẹ̀ (initial self-introduction).

Kíaríbẹ̀ẹ́ (2023) ṣe àtúnpín ìhun-àgbékalẹ̀ orin agbè tí àwọn onímọ̀ wọ̀nyí jírọ̀rò. Ó sì dá àbùdá ìhun-àgbékalẹ̀ orin agbè mẹ́ta yà sọ́tọ̀. Àwọn ìhun-àgbékalẹ̀ wọ̀nyí ni ìṣíde-eré (prelude), eré gan-an (the body of the performance) àti ìdágbére (farewell). Kíaríbẹ̀ẹ́ tún ìṣíde-eré pín sí ìsèlù, ìbà, ìwúre ìbẹ̀rẹ̀ àti ìfira-ẹni-hàn-ìbẹ̀rẹ̀. Ohun tí èyí ń tọ́ka sí ni pé a le fi ìsèlù, ìbà, ìwúre ìbẹ̀rẹ̀ tàbí ìfira-ẹni-hàn-ìbẹ̀rẹ̀ bẹ̀rẹ̀ orin agbè. Òṣèré sì le fi àpapọ̀ gbogbo ìwọ̀nyí bẹ̀rẹ̀. Èyí wà lọ́wọ́ bí òṣèré bá ṣe ní ìmọ̀-ọ́n-ṣe nínú eré ṣíṣe tó. Ìsèlù yìí jẹ́ ìgbésẹ̀ yíyan agbè àti lílu agbè wò láti mọ̀ bóyá agbè náà dún dáradára kí ìṣeré tó tẹ̀ síwájú bí ó ti

yẹ. Ara ìṣeré agbè ni èyí náà, ìdí ni pé bí agbè kò bá dún bí ó ti yẹ kí ó dún, ọ̀kọrin kò le rí orin agbè dá kí ó sì gún régé.

Ó yẹ kí á tún rán wa létí pé àwọn agbè tí a sọ pé àwọn ni ohun èlò ìṣeré wọ̀nyí kì í ṣe ìlù aláwọ. Níorí náà, ó máa ń gba agbára kí onílù agbè tó lù ú láti dún bí ó ṣe yẹ. Bí agbè bá jẹ́ èyí tí a sín, kì í gba agbára tó nǹkan, ṣùgbọ́n bí ó bá jẹ́ pé agbè tí a da ọmọ ìdò tàbí èso tí a fi máa ń sín agbè sí nínú ni, àwọn onílù agbè kì í tètè rí agbè lù, kí ó sì dún bí ó ti yẹ kí ó dún, kí ìṣeré tó bẹ̀rẹ̀ ní pẹrẹu. Nígbà tí àwọn alágbè bá ti ṣíde eré, eré gan-an ni ó kù. Ọ̀nà méjì tí Kíaríbẹ̀ẹ́ pín èyí sí ni ìṣeré ajẹmọ́rọ̀-ẹnu (verbal performance) àti ìṣeré aláìjẹmọ́rọ̀-ẹnu (non-verbal performance). Àwọn ìṣeré ajẹmọ́rọ̀-ẹnu ni oríṣiríṣi orin tí àwọn ọ̀kọrin agbè máa ń kọ. Àwọn èyí tí kò jẹ mọ́ ọ̀rọ̀ ẹnu ni àwọn ìṣeré mìíràn bí agbè lílù, ijó jíjó, òkìtì títa àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Léyìn èyí ni ìdágbére. Àwọn alágbè sì le ṣe èyí náà nípa yálà ìṣeré ajẹmọ́rọ̀-ẹnu tàbí tí aláìjẹmọ́rọ̀-ẹnu.

Àgbéyẹ̀wò ìhun-àgbékalẹ̀ ìṣeré orin kete tí Kíaríbẹ̀ẹ́ (2023) ṣe fi hàn pé ìhun àgbékalẹ̀ àwọn orin méjèèjì wọ̀nyí kò fi bẹ́ẹ̀ yàtọ̀ sí ara wọn. Èyí túmọ̀ sí pé ìhun-àgbékalẹ̀ orin kete tí ó jẹ́ oníhun ìṣíde-eré (prelude), eré gan-an (the body of the performance) àti ìdágbére (farewell) kò yàtọ̀ sí ti orin agbè. Nínú àwọn ọ̀wọ́ ìhun-àgbékalẹ̀ ìṣíde-eré tí Kíaríbẹ̀ẹ́ tún pín, ìsèlù nìkan ni kò sí nínú orin kete; àwọn yòókù máa ń jẹyọ nínú orin náà. Ọ̀nà méjì tí Kíaríbẹ̀ẹ́ pín eré gan-an sí nínú ori agbè náà ni ó pín in sí nínú orin kete; ìṣeré ajẹmọ́rọ̀-ẹnu (verbal performance) àti ìṣeré aláìjẹmọ́rọ̀-ẹnu (non-verbal performance). Àwọn ìṣeré ajẹmọ́rọ̀-ẹnu ni oríṣiríṣi orin tí àwọn ọ̀kọrin kete máa ń kọ. Nínú àwọn tí kò jẹ mọ́ ọ̀rọ̀ ẹnu, idán pápa àti òkìtì títa kò wọ́pọ̀ nínú orin kete bí ó ṣe wà nínú orin agbè nítorí pé orin ìjọ́sìn òrìṣà Alárá-Igbó àti àwọn òrìṣà mìíràn tó jẹ mọ́ ọ̀rọ̀ ọmọ bíbí àti obìnrin ni orin náà níbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀. Bí a bá wo ìhun-àgbékalẹ̀ ìṣeré àwọn orin méjèèjì wọ̀nyí, a le lo àtẹ ìsàlẹ̀ yìí láti fi ìjọra àti ìyàtọ̀ tó wà nínú wọn hàn sí i kedere.

| **Ewì alohùn** | **Ìṣíde-eré** | **Eré gan-an** | **Ìdágbére** |
|---|---|---|---|
| Orin kete | 1. ____________<br>2. *Ìbà*<br>3. *Ìwúre ìbẹ̀rẹ̀*<br>4. *Ìfira-ẹni-hàn-ìbẹ̀rẹ̀*<br>(Ìwọ̀nyí le jẹ́ ìṣeré ajẹmọ́rọ̀-ẹnu tàbí ìṣeré aláìjẹmọ́rọ̀-ẹnu) | 1. Ìṣeré ajẹmọ́rọ̀-ẹnu:<br>Oríkì agbafọ̀ orin, ìdánilárayá, ìdánilẹ́kọ̀ọ́, oríṣiríṣi ìsọ̀rọ̀-ǹ-gbèsì, àwàdà abbl.<br>2. Ìṣeré aláìjẹmọ́rọ́-ẹnu:<br>Òríṣiríṣi àrá dídá nípa àmúlò ohun èlò ìṣeré àti ijó jíjó. | Ìṣeré ajẹmọ́rọ̀-ẹnu àti aláìjẹmọ́rọ̀-ẹnu láti fi parí eré. |
| Orin agbè | 1. *Ìsèlù*<br>2. *Ìbà*<br>3. *Ìwúre ìbẹ̀rẹ̀*<br>4. *Ìfira-ẹni-hàn-ìbẹ̀rẹ̀*<br>(Ìwọ̀nyí le jẹ́ ìṣeré ajẹmọ́rọ̀-ẹnu tàbí ìṣeré aláìjẹmọ́rọ̀-ẹnu) | 1. Ìṣeré ajẹmọ́rọ̀-ẹnu:<br>Oríkì agbáfọ̀ orin, ìdánilárayá, ìdánilẹ́kọ̀ọ́, oríṣiríṣi ìsọ̀rọ̀-ǹ-gbèsì, àwàdà abbl.<br>2. Àwọn ìṣeré aláìjẹmọ́rọ̀-ẹnu:<br>Òríṣiríṣi àrà dídá nípa àmúlò ohun èlò ìṣeré, ijó jíjó, idán pípa àti oríṣiríṣi òkìtì títa | Ìṣeré ajẹmọ́rọ̀-ẹnu àti aláìjẹmọ́rọ̀-ẹnu láti fi parí eré. |

**Àtẹ 1 Àtẹ ìhun àgbékalẹ̀ ìṣeré orin kete àti orin agbè** (Wo Kíaríbẹ̀ẹ́, 2023: 107-110 fún àlàyé kíkún)

Nínú iṣẹ́ yìí, ìṣeré aláìjẹmọ́rọ̀-ẹnu (ijó jíjó) ni a tẹ́pẹlẹ mọ́ gangan-an nínú àwọn ìṣeré orin méjèèjì tí à ń gbé yẹ̀wò. Àwọn ijó tó gbajúmọ́, tí a le rí nínú ìṣeré méjèèjì, èyí tí a jíròrò lé lórí nínú iṣẹ yìí ni ìlù/agbè jíjá, ìdọ̀bálẹ̀/ìyíkàá, fífi-èjìká-jó, ijó àti ilù/agbè lílù papọ̀ lẹ́ẹ̀kan náà àti olóbìíripobírí/ bíripo. Èyí tí ó máa ń jẹ yọ nínú orin kete tí kì í jẹ yọ nínú orin agbè tí a jíròrò lé lórí ni ijó yíyatan-pípatandé. Àwọn ijó tó máa ń jẹyọ nínú orin agbè ṣùgbọ́n tí kì í jẹyọ nínú orin kete tí a ṣe àlàyé lé lórí nínú ìwádìí yìí ni fiwájújó-fẹ̀yìnjó, yọpáyọsẹ̀/ ẹlẹ́yọ-ẹ̀yọ, fò-lálá àti mẹ́tamẹ́ta-ẹ̀là/là-á-mẹ́ta. Èròǹgbà wa ni láti ṣe àtúpalẹ̀ lámèétọ́ nípa àrokò tí wọ́n fi àwọn ijó náà pa nínú ìṣeré orin méjèèjì. Tíọ́rì ìṣeré àti ti ìlò – àmi nínú ewì ni a sì ṣàmúlò fún àgbéyẹ̀wò wa.

**Tíọ́rì ìṣẹ́ré (performance theory)**

Gẹ́gẹ́ bí àlàyé tí Schechner (2004) ṣe, láti ìgbà àtijọ́ ni a ti ń ṣe eré. Èyí a sì máa wáyé ní àsìkò tí àwọn ènìyàn àwùjọ kan bá kó ara wọn jọ sí àwọn àyè tí wọ́n ti yà sọ́tọ̀ láti ṣe àjọyọ̀ ọdún tàbí ìdánilárayá. Àwọn ènìyàn wọ̀nyí máa ń pèsè oúnjẹ àti ohun mímu fún ṣíṣe àjọyọ̀ wọn. Ògúndèjì (2000) ti ṣe irúfẹ́ àlàyé yìí nípa àwọn ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá síwájú. Ògúndèjì sọ pé àjọyọ̀ tí àwọn ènìyàn ilẹ̀ Áfíríkà máa ń ṣe wọ̀nyí máa ń wáyé ní àwọn àyè bí ojúde ààfin ọba, ẹ̀bá odò, inú igbó ìgbàlẹ̀/ orò, àárín ọjà, oríta mẹ́ta àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ògúndèjì rí irúfẹ́ àwọn ìṣeré tí ó máa ń wáyé ní irúfẹ́ àwọn àyè bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ bí akitiyan eré-oníṣe. Èrò Schechner (2024) ni pé gbogbo akitiyan àwọn ará àtijọ́ láti dáni lárayá nínú àwọn ọdún ìbílẹ̀ wọn jẹ́ akitiyan ìṣeré. Èyí sì ni Ògúndèjì (1991 & 2000) gbà pé a lè pè ní eré-oníṣe abínibí tàbí àdáyébá ní ilẹ̀ Adúláwọ̀.

Sonnentag (2002) jẹ́ kí á mọ̀ pé tíọ́rì ìṣeré jẹ́ olọ́pọ̀-ẹ̀dá, ìdí ni pé tíọ́rì náà jẹ mọ́ ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹka-ìmọ̀. Nítorí pé ìṣeré a máa ṣamúlò ọ̀pọ̀ ọnà papọ̀ lẹ́ẹ̀kan náà, pàápàá ní ilẹ̀ Áfíríkà, ni ó ṣe nílò tíọ́rì ajẹmọ́pọ̀-ẹ̀ka-ìmọ̀. Nínú ìṣeré orín kete àti orin agbè, bí àpẹẹrẹ, lára àwọn ọnà ìṣeré tí wọ́n péjú-pésẹ̀ síbẹ̀ ni orin kíkọ, ìlù/ agbè lílù, ijó jíjó, idán pípa, àti òkìti títa. Ó yẹ kí á yán an pé ọnà ìṣeré mẹ́ta àkọ́kọ́ jẹ mọ́ ìṣeré orin méjèèjì, nígbà tí méji tó gbẹ̀yìn jẹ mọ́ orin agbè nìkan. Ìdí nìyí tí àwọn ìṣeré orin náà fi jẹ́ ọlọ́pọ̀-ọnà. Sonnentag gbà pé ìṣeré (tàbí akitiyan láti ṣe eré) gbòòrò ju tíátà lọ. Ohun tí ó mú un sọ báyìí ni pé kì í ṣe tíátà nìkan ni ó jẹ mọ́ ìṣe (action). Gbogbo ohun tí ó bá ti jẹ mọ́ ìṣe tàbí ṣíṣe-nǹkan-hanni ni ìṣeré jẹ mọ́ nígbà, tí ó jẹ́ pé eré ṣíṣe lorí ìtàgé tàbí ní ojútáyé nìkan ni tíátà jẹ mọ́. Láti ṣe àlàyé èrò Sonnentag yìí síwájú sí i, ohun tí a lérò pé onímọ̀ náà ń sọ ni pé kì í ṣe pé nínú ẹka-ìmọ̀ tíátà nìkan ni akitiyan ìṣeré wà. Àwọn tí ó ń kọ́ nípa ọnà sọ̀rọ̀sọ̀rọ̀, ìwàásù, ìròyìn kíkà, lítíréṣọ alohùn, orin kíkọ, àwàdà ṣíṣe láti dá òǹwòran lárayá àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ náà máa ń ṣe àmúlò ìṣeré. Eré ṣíṣe gan-an ni àwọn tó wà ní ẹka-ẹ̀kọ́ orin kíkọ náà fi máa ń perí ìdánilárayá tí wọ́n máa ń ṣe. Òṣèré náà sì ni à ń pè wọ́n. Láti fi ìyàtọ̀ irúfẹ́ òṣèré tí ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn tó ń ṣeré jẹ́ hàn ni a ṣe máa ń fi ọ̀rọ̀ àpèjúwe ṣe ìyàtọ̀ wọn gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ; òṣèré orí-ìtàgé, òṣèré orin jùjú, òṣèré orin àpàlà, òṣèré eléégún aláré, òṣèré oníjó, òṣèré onílù àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Bí a bá wá wo àlàyé wa nípa tíátà (theatre) àti ìṣeré (performance) yìí, kò ṣókùnkùn pé nínú akitiyan láti ṣe eré ni tíátà ti jẹ yọ. Torí pé ìṣeré (performance) tún jẹ mọ́ àwọn akitiyan eré ṣíṣe mìíràn yàtọ̀ sí tíátà ni a ṣe fara mọ́ èrò Sonnentag (2002) tó sọ pé ìṣeré fẹ́jú ju tíátà lọ. Bí a bá wá ní ká wo èwo nínú tíọ́rì/ ìmọ̀ méjèèjì yìí ni ó ṣíwájú gbajúmọ̀ láwujọ akadá, kò níyàn nínú pé ti tíátà ti ṣíwájú àti pé lára èrò ọ̀tun nípa àwùjọ, ìmọ̀ ìjínlẹ̀ nípa ìbágbépọ̀, wíwalẹ̀pìtàn, lítíréṣọ̀ àti àṣà ni tíọ́rì ìṣeré ti jẹ yọ (Auslander, 2008).

Ewì alohùn Yorùbá jẹ mọ́ ìṣeré (Ògúndèjì, 1991), nípa ṣíṣe àwọn lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá ni ẹwà wọn fi le yọ (Ògúndèjì, 2000 & Kíaríbẹ̀ẹ́, 2023). Àwọn ewì alohùn Yorùbá kan jẹ mọ́ ẹ̀sìn, àwọn kan kò sì jẹ mọ́ ẹ̀sìn ìbílẹ̀ Yorùbá (Ògúndèjì, 1991, Ọ̀pádọ̀tun, 2002 & Kíaríbẹ̀ẹ́, 2023). Àwọn tó jẹ mọ́ ẹ̀sìn ìbílẹ̀ wọ̀nyí ni a sábà máa ń ṣe ní àsìkò àwọn ọdún

ìbílẹ̀ tí Schechner (2004) tọ́ka sí pé ìṣeré máa ń jẹ yọ nínú wọn. Orin kete jẹ mọ́ ẹ̀sìn, a sì máa ń ṣe eré orin yìí lásìkò ọdún òrìṣà Ẹgbé, Ọbàtálá, Ìrókò, Ìbejì, Ọ̀ṣun, Kórìkótò àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Orin agbè kò jẹ mọ́ ẹ̀sìn ṣùgbọ́n a le kọ ọ́ lásìkò ọdún tí kò jẹ mọ́ ẹ̀sìn, bí àsìkò ọdún Bẹrẹ tí àwọn Aláàfin máa ń ṣe ní ayé àtijọ́. A le kọ ọ́ níbi ayẹyẹ ọdún tí ó jẹ mọ́ ẹ̀sìn náà fún ìdáraráyá pọ́nńbélé. Ìdí nìyí tí Àlàbá (1985) fi pe orin yìí ní ọlọ́pọ̀-ìlò.

**Tíọ́rì ìlò-àmì nínú ewì (semiotics of poetry)**

Láti ìgbà láéláé ni ìṣàmúlò àmì tàbí àròkò fún ìbánisọ̀rọ̀ tí wà. Kò sí ẹni tí ó le sọ pàtó pé nígbà báyìí ni àṣà yìí bẹ̀rẹ̀, pàtàkì jùlọ ní ilẹ̀ Áfíríkà. Kò sí àwùjọ kan tí kò ní ìlànà tí wọ́n ń gbà lo àmì láti báni sọ̀rọ̀. Bí a bá ń sọ̀rọ̀ tíọ́rì ìlò àmì àwọn onímọ̀ méjì tí a sábàá máa ń dárúkọ jù lọ ni Ferdinand de Saussure (1857 – 1913) àti Charles Sanders Peirce (1839 – 1914). Lórí ìmọ̀ ẹ̀dá èdè ni iṣẹ́ Ferdinand de Saussure dá lé. Ìmọ̀ filọ́sọ́fì tàbí èrò-ìjìnlẹ̀ sì ni Charles Sander Peirce gbé àlàyé rẹ̀ lórí ìlò àmì lé. Kókó òpó tíọ́rì yìí tí a fẹ́ láti mú lò nínú iṣẹ́ wọn ni ìgbágbọ̀ wọn nípa pé; ohun kan a máa dúró fún òmíràn nínú ìlò àmì àti pé ìmọ̀ ìlò àmì ni a fi ń ṣe àlàyé òfin tí ó de lílò rẹ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀nà ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni wọ́n gbà láti sọ èyí, àwọn onímọ̀ méjèèjì yìí ni wọ́n gbà pé ohun tí a fi sàmì tàbí pa àrokò máa ń yàtọ̀ sí ìtumọ̀ rẹ̀.

Umberto Eco (1976) gbà pé kò sí ohun tí kò le dúró gẹ́gẹ́ bí àmì/ àrokò. Ògúndèjì (1988), tí ó wà lára àwọn onímọ̀ ilẹ̀ Áfíríkà tí ó kọ́kọ́ lo tíọ́rì ìlò-àmì fún àtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ Yorùbá náà nígbàgbọ́ nínú erò yìí nígbà tí ó sọ pé àmì le jẹ́ ohunkóhun. Bí a bá lo ohun kan gẹ́gẹ́ bí àmì, ìtumọ̀ ohun náà tún le jẹ́ àmì fún ohun mìíràn, èyí tí ó máa ń fa àlékún ìtumọ́ nínú ìgbésẹ̀ láti túmọ̀ àmì (Cobley, 2005). Ó yẹ kí á tọ́ka sí i pé lára àlàmọ́lẹ̀ inú tíọ́rì ìlò àmì ni pé ìmọ̀, ìròrí àti àṣà àwùjọ máa ń kó ipa pàtàkì nínú fífún àmì ní ìtumọ̀ bí Yuri Lotman (1990) ti sọ. Ohun tí onímọ̀ yìí ń sọ ni òfin tí a tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan nínú àwọn ohun tí èrò Ferdinand de Saussure àti Charles Sanders Peirce dá lábàá lókè. Dandan ni kí ẹni tí a pàrokò àmì kan sí ní ìmọ̀ nípa àmì tí a pa lárokò sí i àti òfin tí ó de ìlò àmì náà. Bí agbàrokò kò bá nímọ̀ nípa ohun tí a fi pàrokò sí i, kò sí bí yóò ti ṣe mọ ohun tí àmì túmọ̀ sí. Bí èyí bá rí bẹ́ẹ̀, a jẹ́ pé ìbára-ẹni-sọ̀rọ̀ kò lè kẹ́sẹjárí láàárín apàrokò àti agbàrokò nìyẹn. Ìdí nìyí tí Lotman tún fi tẹ̀ síwájú pé àmì tí a fi pàrokò máa ń ní í ṣe pẹ̀lú ohun kan tàbí òmíràn nínú àṣà àwùjọ tí a ti pàrokò náà.

Lotman tún fi kún ọ̀rọ̀ rẹ̀ pé àwọn àyè kan wà tí ó jẹ́ pé àrokò kan pàtó ni àyè bẹ́ẹ̀ máa ń pa. Lotman tọ́ka sí i pé àwọn àyè wọ̀nyí sábà máa ń jẹ́ àyè àtijọ́, èyí tí ìgbágbọ́ àtì ẹ̀sìn àwọn ènìyàn àwùjọ kan rọ̀ mọ́. Bí a bá wo èrò Lotman yìí, àkàwé rẹ̀ bá àwọn ibi ìṣeré tí eré tí máa ń wáyé nínú àwọn eré ọdún ìbílẹ̀ tí a ti dárúkọ lókè yẹn mu. Bí ìránni létí, irú àwọn àyè bẹ́ẹ̀, paápàá láàrin àwọn Yorùbá, ni ojú ọjà, ààrin gbùngbùn ìlù, ojúbọ̀ òrìṣà, ojúde ààfin ọba, ìgbórò, igbó ìgbàlẹ̀ abbl. Àwọn wọ̀nyí jẹ́ àpẹẹrẹ àwọn àyè pàtàkì tí ìṣeré tí máa ń wáyé nínú eré ọdún ìbílẹ̀ tí a sọ pé Ògundèjì (2020) tọ́ka sí. Irú àwọn àyè tí a yà sọ́tọ̀ bẹ́ẹ̀ ni a lè ka ojú ẹgbẹ́ tí ìṣeré orin kete ti lè wáyé sí. Ohun kan tí ó yẹ kí á pe àkíyèsí sí ni pé kò sí àyè tí a kò ti lè pàtẹ àwọn ìṣeré aláìjẹmẹ́sìn ni tirẹ̀; kí ibẹ̀ ṣá ti tẹ́jú kí ó jẹ́ ìta gbangba níbi tí àyè yóò ti gba tòṣeré ti òǹwòran..

Àtòjọ kóòdù ni lítíréṣọ̀ jẹ́ (Eco, 1976 & Ògúndèjì, 1988). Àmúlò èdè nínú ewì yàtọ̀ sí bí a ṣe ń lo èdè ní ìlànà ojoojúmọ́; ewì ní bátànì èdè tirẹ̀ (Jakobson, 1960 & Ọlátẹ́jú, 1998). Èyí ni Michael Riffaterre (1978) rí tí ó fi sọ pé nínú ewì ni ìlò àmì ti wọ́pọ̀ jù lọ. Ó sọ pé àwọn ọ̀rọ̀ tí a ti pa tì nínú èdè ojojúmọ́ ni a tún máa ń mú lò nínú ewì. Ìdí nìyí tí ó fi dábàá pé ọ̀nà méjì ni ó wà fún kíka ewì. Àkọ́kọ́ ní kíkà ti eréfèé, èkejì sì ni kíkà ti ìjìnlẹ̀ kí kókó ohun tí ewì ń sọ le yéni dáradára. Riffaterre tún ṣe àlàyé pé èdè ìpìlẹ̀ tí kò rújú, ṣùgbọ́n tí a yídà sọ di èyí tí ó le koko, tí ó sì rújú ni ewì jẹ́. Nítorí náà, láti ní àgbọ́yé nípa kókó ohun tí ewì ń sọ, agbafọ̀ ewì gbọ́dọ̀ lè tọpa èdè ewì lọ sí inú ìhun ìpìlẹ̀ tí a ti ṣẹ̀dá rẹ̀. Àwọn àmì kan wà tí ó máa ń jẹ yọ nínú ewì ṣùgbọ́n tó jẹ́ pé wọ́n ti jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà karí-ayé. Àwọn àmì wọ̀nyí ni Riffaterre pè ní ọ̀rọ̀ ìkàsì (*cliché*). Ohun tí onímọ̀ yìí ń tọ́ka sí níbí ni pé irúfẹ́ àwọn

àmì tí ìtumọ̀ wọn jẹ́ kárí-ayé báwọ̀nyí kò yẹ kí ó mú ìrújú wá. Èrò tiwa ni pé kò sí ohun tí oníṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀ kò le sọ di ohun bàbàrà nínú iṣẹ́-ọ
nà rẹ̀, èyí wà lọ́wọ́ bí oníṣẹ́-ọnà náà bá ti ní ìmọ̀-ọ́n-ṣe tó nínú àmùlò-èdè.

Riffaterre gbà pé àwọn àmì onítúmọ̀-pọ́nna (dual signs) máa ń jẹyọ nínú ewì. Èyí ni kí àmì kan ní ju ìtumọ̀ kan ṣoṣo lọ. Bí a bá wo àwọn ìṣeré ewì alohùn Yorùbá, ohun kan ṣoṣo a máa ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìtumọ̀ nígbà míràn. Ìtúmọ̀ wọ̀nyí sì máa ń ní í ṣe pẹ̀lú ọ̀gangan ipò àti àsìkò ìṣeré tí òṣèré bá ti lo àmì náà. Bákan náà, Riffaterre ka ọ̀rọ̀ agbafọ̀ àmì sí pàtàkì nínú ewì. Agbafọ̀ tí òye rẹ̀ kò bá tó nǹkan kò le mọ ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìtumọ̀ àwọn àmì tí a lò nínú ewì (b.a. nínú lítíréṣọ̀ alohùnYorùbá). Riffaterre tún ka àwọn àmì kan sí àmì/ kóòdù aláìnítumọ̀. Àwọn wọ̀nyí ni kóòdù tó jẹ́ pé wọn kò le dá ìtumọ̀ ara wọn ni, àyàfi nípasẹ̀ bí a ṣe lò wọn pẹ̀lú àwọn kóòdù mìíràn ní ọ̀gangan ipò ìṣàmúlò wọ́n ni a ṣe le fún wọn ní ìtumọ̀. Kò yẹ kí èyí jọ wá lójú nítorí pé a ti sọ síwájú pé ohun kékeré ni àwọn akéwì máa ń fẹ̀ lójú, tí wọn sì máa ń sọ di bàbàrà nínú ewì.

Oríṣiríṣi àmì tó jẹ mọ́ ẹ̀sìn, ìtàn, ìgbé-ayé, ìgbàgbọ́, ìṣesí àti ìbágbépọ̀ ni ó máa ń jẹ yọ nínú ìṣeré orin kete àti orin agbè. Ìdí nìyí tí ó fi yẹ kí á ti ibí pe àkíyèsí sí i, gẹ́gẹ́ bí àwọn onímọ̀ ìlò àmì ti gbàgbọ́, pé gbogbo ohun tí ó máa ń jẹ yọ nínú ìgbésí ayé àwọn ènìyàn àwùjọ tí ìṣeré kan ti í wáyé náà ni a le fi pàrokò nínú ìṣeré náà. Èyí rí bẹ́ẹ̀ torí pé ọ̀kan lára ọ̀nà ìgbé-ayé àwọn ènìyàn ilẹ̀ Áfíríkà, ní pàtàkì jùlọ, àwọn ènìyàn ilẹ̀ Yorùbá ni a ka lítíréṣọ̀ wọn sí.

**Oríṣiríṣi ijó tí ó máa ń jẹ yọ nínú ìṣeré orin kete àti orin agbè**

Ọ̀kan pàtàkì nínú àṣà ìdánilárayá tí ó rọ̀ mọ́ orin kíkọ ni ijó jíjó. Àwọn Yorùbá máa ń jó sí orin tí wọ́n bá ń kọ. Àwọn òṣèré kan tilẹ̀ wà tí ó jẹ́ pé oníjó pọ́nńbélé ni wọ́n. Irú òṣèré tó jẹ́ oníjó báyìí ni Ìyàwó agbè nínú orin agbè àti Abọ̀yẹ̀rì nínú orin kete (wo Ògúndèjì, 1979 àti Kíaríbẹ̀ẹ́, 2023 fún àlàyé kíkún lórí àwọn òṣèré wọ̀nyí). Kì í ṣe àwọn oníjó tí a dárúkọ wọ̀nyí nìkan ni í máa jó nínú orin kete àti orin agbè, àwọn òṣèré mìíràn náà máa ń jó; àwọn onílù/ alágbè àti ọ̀kọrin náà le jó. Yàtọ̀ sí pé àwọn òṣèré mìíràn le jó nínú orin méjèèjì, àwọn agbàrokò inú orin àti àwọn òǹwòran yòókù náà lè jó. Èyí a máa wọ́pọ̀ nígbà tí a bá fi orin kì wọ́n tàbí tí eré náà bá dùn mọ́ wọn. Ẹ jẹ́ kí á kọ́kọ́ jíròrò lórí àwọn oríṣi ijó tí a sọ pé a máa jẹyọ nínú ìṣeré orin kete àti orin agbè.

**Áwọn ijó tí í máa á jẹyọ nínú ìseré àwọn orin méjèèjì**

Gẹ́gẹ́ bí ìránnilétí àwọn ijó márùn-ún tí a sọ pé wọ́n máa ń jẹyọ nínú ìṣeré tèkínní-tèkejì àwọn orin náà ni ìlù/agbè jíjá, ìdọ̀bálẹ̀/ìyíkàá, fífi-èjìká-jó, ijó jíjó àti ilù/agbè lílù papọ̀ lẹ́ẹ̀kan náà àti olóbìírípobírí/ bírípo.

**Ìlù/ agbè jíjá**

Nínú ìṣeré orin kete ni ìlù jíjá ti máa ń jẹ yọ. Ìlù gidi tí a fi awọ sè ni ìlù kete àti bẹ̀ǹbẹ́ tí à ń lù sí orin náà. Ẹ̀wẹ̀, agbè jíjá ni ó máa ń jẹ yọ nínú orin agbè. Agbè, bí a ti ṣe sọ, kì í ṣe ìlù àláwọ rárrárárá; èso/ ọmọ ìdò tàbí èso mìíràn tí ó le koko ni a fi máa ń sín in, tàbí kí á rọ ọ́ sínú rẹ̀. Ìlù jíjá ni kí oníjó máa darí ẹ̀yà ara rẹ̀, bí ọwọ́ ẹsẹ̀, tàbí ẹ̀yà ara mìíràn láti ṣe wẹ́kú pẹ̀lú dídáwọ́ ìlù/ agbè dúró díẹ̀ ní iye ìgbà kan; èyí le jẹ́ ìgbà kan ṣoṣo, ìgbà mẹ́ta tàbí ìgbà méje. Ìgbà mẹ́ta ni ó wọ́pọ̀ jù nínú ìlù jíjá. Bákan náà ni a le dáwọ́ agbè lílù náà dúró ní ìdágbáǹdágbá kí oníjó le já ọwọ́, ẹsẹ̀, tàbí ẹ̀yà ara mìíràn láti ṣe wẹ́kú pẹ̀lú dídáwọ́ agbè lílù náà dúró. Àṣà ìlù jíjá wọ́pọ̀ nínú ijó ìlù bàtá. Àwọn Oníṣàngó ni ó máa ń jó bàtá jùlọ. Bí wọ́n bá sì ti ń jó ijó yìí ni wọ́n máa ń já ìlù náà nípa ẹsẹ̀ títa. Èyí ló fa á tí àwọn Yorùbá fi máa ń pa òwe pé, “Oníṣàngó tó jó bàtá tí kò ta ìpá, àbùkù ara rẹ̀ ni.” Bàtá jíjá ni òwe yìí tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí ìpá títa yìí. Àwọn eléégún aláré náà a máa jó bàtá, wọ́n sì wà lára àwọn òṣèré tí Yorùbá gbà pé wọ́n mọ ijó jó jùlọ. Àwọn òṣèré ewì alohùn tó jẹ́ eléégún aláré ni àwọn Yorùbá fi máa ń pa àṣamọ̀ ijó jíjó jùlọ. Àpẹẹrẹ àwọn òṣèré eégún aláré bẹ́ẹ̀ ni Lébe àti Ẹyẹ́bà.

Láti já ìlù nínú ìṣeré orin kete, òṣèré le dá oríṣiríṣi àrà. Ó le wà ní òòró, ó le wà ní ìkúnlẹ̀ tàbí ìdọ̀bálẹ̀. Òṣèré le fi apá já ìlù kete, ó le fi ẹsẹ̀ já ìlù, ó le fi orí já a, ó sì le fi èjìká já a. Èyí wà lọ́wọ́ bí òṣèré bá ṣe mọ ijó jó tó, àti bí ó ṣe gbọ́ ohùn ìlù kete tó. Àpẹẹrẹ àwòrán ìlù jíjá nínú orin kete nìyí nínú àwòrán onífọ́tò 1 àti 2 ìsàlẹ̀ yìí:



**Àwòrán 1:** Ìlù jíjá lórí ìkúnlẹ̀



**Àwòrán 2:** Ìlù jíjá nípa kíká ẹsẹ̀ kan sókè

Nínú àwòrán 1, abọ̀yẹ̀rì ni ó ń já ìlù lórí ìkúnlẹ̀. Bí ó ṣe ń já ìlù yìí ni ó ń sún sí iwájú, bẹ́ẹ̀ kò sì kúrò lórí ìkúnlẹ̀ náà. Àwòrán kejì jẹ́ ti òǹwòran kan àti abọ̀yẹ̀rì ṣùgbọ́n òǹwòran náà ni eré wọ̀ lára tí ó sì bẹ̀rẹ̀ sí ní í já ìlù. Ìgbà tí ìlù jíjá náà ká a lára, ó fi ọwọ́ rẹ̀ májẹ̀ẹ̀jì múlẹ̀, ó sì ká ẹsẹ̀ rẹ̀ kan sókè láti fi já ìlù. Nítorí pé orí ìkúnlẹ̀ ni abọ̀yẹ̀rì wà tí ó fi ń já ìlù tirẹ̀ nínú àwòrán 1, ara oríṣi ijó kan (ìyíkàá) tí àwọn òṣèré orin kete fi máa ń júbà Alárá-Igbó ni a tún le ka irúfẹ́ ìlù jíjá yìí kún, nítorí náà, àmì ìbọ̀wọ́fún, ajẹmẹ́sìn ni oríṣi ìlù jíjá yìí nínú orin kete. Ìlù jíjá kejì, ti inú àwòrán 2 ni a le pè ní àmì fífi ìtẹ́lọ́rùn adùn eré hàn torí pé ìgbà tí adùn eré náà tó tẹ́ òǹwòran yìí lọ́rùn ní ó tó ṣe báyìí.

Nínú ìṣeré orin agbè, agbè jíjá wọ́pọ̀ púpọ̀ ju ìlù jíjá ti inú orin kete lọ. Ó fẹ́rẹ̀ jẹ́ pé gbogbo ìgbésẹ̀ ijó orin agbè ló jẹ mọ́ agbè jíjá. Ohun tí alérò pé èyí fi rí bẹ́ẹ̀ ni pé àbàrá tí a má ń kó bo agbè máa ń jẹ́ kí ó rí bí ẹni pé jíjá ṣáá la fẹ́ kí ajágbè máa já a. Oríṣi agbè kan tí a pè ní pẹ̀ǹpẹ̀kun/ pẹ̀ǹpẹ̀ a tilẹ̀ máa dún ní dídún tí yóò fi han oníjó pé kó sá máa já agbè náà láì dáwọ́ dúró ni. Lẹ́yìn ìyá agbè, pẹ̀ǹpẹ̀kun yìí ni àwọn ajágbè tún máa ń já jùlọ nínú orin agbè. Jíjá pẹ̀ǹpẹ̀kun yìí tún ń fún àwọn onílù agbè ní àǹfààní láti jó sí ìwéhùn orin kí wọ́n má baà sọ ìṣewẹ́kú ohùn orin àti ti agbè nù bí wọ́n ti ń ṣeré. Ohun tó tún jọjú nínú agbè jíjá ni pé kò sí agbè tí oníjó kò le já ní ọ̀kọ̀ọ̀kan nínú àwọn ọ̀wọ́ ìlù agbè. Òṣèré tó mọ tifuntẹ̀dọ̀ agbè lílù nìkan ló le sọ pàtó èwo nínú ọ̀wọ́ ìlù agbè ni ajágbè ń já gan-an.

Ajágbè a tún máa fi agbè tó ń já hàn nípa sísún mọ́ onílù tó ń lu agbè yìí kí ó le jó o dáradára. Ṣíbẹ̀ náà, ìyá agbè ni àwọn ajágbè sábàà máa ń já jùlọ bí a ti sọ tẹ̀lẹ̀. Agbè tó sì tẹ̀lé e, tí wọ́n máa ń já, ni pẹ̀ǹpẹ̀kun/ pẹ̀ǹpẹ̀ tí a ti dárúkọ. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ agbè jíjá inú àwòrán onífọ́tò 3 àti 4  ìsàlẹ̀ yìí:



**Àwòrán 3:** Oníjó na ẹsẹ̀ àti ọwọ́ rẹ̀ òsì sí ẹ̀gbẹ́ kan láti já agbè



**Àwòrán 4:** Oníjó na owọ́ rẹ̀ méjèèjì àti ẹsẹ̀ rẹ̀ òsì sí iwájú láti já agbè

Bí a bá wo àwọn oníjó orin agbè méjèèjì tí a fi hàn nínú àwòrán 3 àti 4 yẹn, níṣe ni wọ́n na ọwọ́ wọn àti ẹsẹ wọn láti já agbè. O hàn kedere pé oníjó inú àwòrán 3 múra sí ijó tí ó ń jó gidigidi; gbogbo agbára àti ipá rẹ̀ ni ó fi ń jó o, ṣùgbọ́n bí ẹni ń jó ijó gbẹ̀fẹ́ ni oníjó inú àwòrán 4 ṣe ń já agbè ní tirẹ̀. Pẹ̀ǹpẹ̀kun ni ajágbè inú àwòrán 3 ń já ṣùgbọ́n ìyá agbè ni ajágbè inú àwòrán 4 ń já ní tirẹ̀. Àwọn méjèèjì ní ó ń tẹ̀lé ìwọ́hùn agbè tí wọn ń jó náà láti fi hàn pé òṣèré agbófèé ni àwọn. Nípa ṣíṣe báyìí, àmì ìmọ̀-ọ́n-ṣe nínú ijó àti gbígbọ́ ohùn agbè ni èyí jẹ́. Jíjá pẹ̀ǹpẹ̀kun gẹ́gẹ́ bí oníjó ṣe ṣe nínú àwòrán 3 jẹ́ àmì bíbá ìwéhùn agbè lọ. Nítorí pé pẹ̀ǹpẹ̀kun yìí ṣòró ó já, tí ó sì pọn dandan kí jíjá rẹ̀ bá ìwọ́hùn agbè lọ, ó nílò agbára àti ipá.Àmì ipá àti agbára lílò láti já ìlù agbè ni pẹ̀ǹpẹ̀kun jíjá tún dúró fún nínú orin agbè. Ìyá agbè jíjá kò gba agbára àti ipá bí jíjá pẹ̀ǹpẹ̀kun ní tirẹ̀.

**Ìdọ̀bálẹ̀/ ìyíkàá**

Lára àṣà ìkíni Yorùbá ni ìdọ́bálẹ̀ nínú àṣà àdáyébá abínibí Yorùbá, ó sì jẹ́ àmì ìbọ̀wọ̀-fágbà àti ajuni-lọ, Àwọn ọkùnrin ní í máa dọ̀bálẹ̀ láti kí àgbàlagbà. Ìkúnlẹ̀ ni àwọn obìnrin Yorùbá máa ń fi kí àwọn ajunilọ ní tiwọn. Àṣà yìí máa ń jẹ yọ nínú orin agbè. Ìyíkàá ní tirẹ̀ jẹ́ oríṣi ìkíni àti ìbọ̀wọ̀fún kan tó jẹ́ pé orí ìkúnlẹ̀ ni ẹni tí ó ń yíkàá náà yóó ti máa yí sọ́tùn-ún, yí sósì níwájú ẹni tí ó juni lọ. Ìdọ̀bálẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ijó máa ń jẹ yọ nínú orin agbè nígbà tí oníjó bá dọ̀bálẹ̀ tí ó sì ń jó lórí ìdọ̀bálẹ̀ yìí. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ àwòrán onífọ́tò 5 àti 6:

sì



**Àwòrán 5:** Oníjó orin agbè dọ̀bálẹ̀ láti júbà



**Àwòrán 6:** Oníjó orin agbè mìíràn dọ̀bálẹ̀ láti júbà

Àwòrán àwọn oníjó méjèèjì inú fọ́tò 5 àti 6 yìí fi hàn pé wọ́n dọ̀bálẹ̀. Kì í ṣe pé wọ́n kàn dọ̀bálẹ̀ lásán ṣá, ijó ni wọ́n jó títí, kí wọ́n tó wá parí ijó náà sí orí ìdọ̀bálẹ̀ ní ẹ̀ẹ̀kan náà. Bí wọ́n ṣe wà lórí ìdọ̀bálẹ̀ yìí náà ni wọ́n tún ń fi ara jó. Àmì ìbọ̀wọ̀ fún àwọn àgbàlagbà tó wà ní ìkàlẹ̀ ni èyí jẹ́. Nínú orin tí wọ́n máa ń kọ sí ijó yìí tí ó sì fi ẹsẹ̀ àrokò ìbọ̀wọ̀fágbà tí wọ́n fi ijó náà pa múlẹ̀ ni:

Lílé: Ìdọ̀bálẹ̀ oooo
Gbígbè: La fi ń kí baba
Lílé: Ìdọ̀bálẹ̀ oooo
Gbígbè: Lọmọ ń kí baba (Ògundèjí 1979)

Nínú orin kete ni ìyíkàá wọ́pọ̀ sí jùlọ ṣùgbọ́n a máa jẹ yọ nínú orin agbè náà. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ rẹ̀ nínú àwọn àwòrán onífọ́tò 7 àti 8:



**Àwòrán 7:** Ìyíkàá nínú orin kete



**Àwòrán 8:** Ìyíkàá nínú orin agbè

Láti jó ijó ìyíkàá nínú orin kete gẹ́gẹ́ bí a ṣe fi àwòrán rẹ̀ hàn nínú àwòrán 7 òkè yẹn, abọ̀yẹ̀rì-kete fi orókún rẹ̀ òsì kúnlẹ̀, ó wá mú èjìká rẹ̀ òsì lọ sí ilẹ̀ lẹ́yìn tí ó ti na ẹsẹ̀ ọ̀tún rẹ̀ dáradára, ó sì ń fi ẹsẹ̀ ọ̀tún rẹ̀ tó nà náà jó yípo títí tí orókún tí ó fi lé ilẹ̀ náà fi sàmì roboto yípo ọ̀gangan àyè tí ó ti ń jó náà. Ó ṣe èyí láti fi júbà àwọn òrìṣà tó jẹ mọ́ orin kete ni; ní pàtàkì jùlọ, Alárá-Igbó. A lè sọ pé ipa/ ìlà roboto tí orókún rẹ̀ là kalẹ̀ dúró fún ojú ẹgbẹ́, níbi tí àwọn olùsìn Alárá-Igbó tí máa ń pàdé. Ojú ẹgbẹ́ yìí ni àwọn olùsìn Alárá-Igbó, àwọn ẹgbẹ́, máa ń tọ́ka sí nígbà tí wọ́n bá ń kọrin pé:

| | |
|---|---|
| Lílé: | Ìràwé mò ń gbá lójú ẹgbẹ́ |
| | Lọmọ fò mọ́mi láṣọ |
| Gbígbè: | Ìràwé mò ń gbá lójú ẹgbẹ́ |
| Lílé: | Lọmọ fò mọ́mi láṣọ |
| Gbígbè: | Ìràwé mò ń gbá lójú ẹgbẹ́ |
| Lílé: | Ẹ kóbẹ̀ kọ́mọ rí mi |
| Gbígbè: | Ìràwé mò ń gbá lójú ẹgbẹ́ .... |

Ojú ẹgbẹ́ jẹ́ àyè tí àwọn olórìṣà náà tí máa ń tọrọ ọmọ àti ohun gbogbo tí wọ́n bá fẹ́ lọ́wọ́ ẹgbẹ́ wọn ọ̀run. Òrìṣà Alárá-Igbó tí àwọn olùsìn wọ̀nyí ń sìn ni àwọn ènìyàn kan tún ń pè ní Ìyálóde (ẹgbẹ́), ẹni tí ó jẹ́ alága gbogbo ẹgbẹ́ ọ̀run.

Ìyíkàá tí ó jẹ yọ nínú orin agbè jẹ́ àmì ìbọ̀wọ̀ fún àwọn àgbààgbà àti àwọn olórí bákan náà. Nínú àṣà Yorùbá, a máa ń yíkàá fún àwọn ọba alayé, a sì máa ń kúnlẹ̀ pa igúnpá mọ́, kí á sì ba búrúbúrú láti fi ọ̀wọ̀ fún àwọn ọba aláyé. Níwọ̀n ìgbà tí ó jẹ́ pé orin ọba ni orin agbè jẹ́ láti ìpìlẹ̀ rẹ̀ wá bí a ti sọ ṣaájú, kò yani lẹ́nu rárá pé ijó ìyíkàá jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára ijó àwọn ajágbè. Wọ́n máa ń lò ó láti fi kí ọba lásìkò ìṣeré wọn. Lọ́rọ̀ kan ijó ìyíkàá àti ìdọ̀bálẹ̀ nínú àwọn ìṣeré orin méjèèjì jẹ́ àmì ìjúbà, ìbọ̀wọ̀fágbà àti ajunilọ.

**Fífi-èjìká-jó**

Oríṣi ijó kan tí ó gbajúmọ̀ nínú orin agbè àti orin kete ni ijó fífi-èjìká-jó yìí. Àwọn ajókete, èyí tí abọ̀yẹ̀rì-kete jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú wọn, máa ń fi èjíká jó. Wọ́n sì máa ń fi èjìká yìí já ìlù. Abọyẹ̀rì sábàá máa ń ṣe èyí lásìkò tí ó bá wà lórí ìkúnlẹ̀ yálà nígbà tó bá parí ìyíkàá tàbí tí ó bá ń ṣe ìyíkàá yìí lọ́wọ́. Fífi-èjìká-jó wọ́pọ̀ nínú orin agbè ju orin kete lọ. Èjìká ni àwọn onílù agbè fi máa ń jó agbè lásìkò tí wọ́n bá ń lù ú lọ́wọ́. Bákan náà ni pé àwọn oníjò mìíràn fẹ́ràn láti máa fi èjìká jó, kò sì sí ìgbà tí èyí kì í wáyé nínú orin agbè. Ẹ jẹ́ kí á wo àwọn àwòrán inú fọ́tò 9 àti 10 ìsàlẹ̀ yìí fún àpẹẹrẹ bí àwọn òṣèré orin kete àti orin agbè ṣe ń fi èjìká jó.




**Àwòrán 9:** Obìnrin oníjó agbè ń fi èjìká jó

Èjìká ni oníjó inú àwòrán fọ́tò 9 yìí fi ń já ìyá ìlù agbè; èyí ni ó mú kí ó ká ọwọ́ ọ̀tún rẹ̀ kò, kí ó sì gbé èjìká apá ọ̀tún rẹ̀ kan náà sókè papọ̀ lẹ́ẹ̀kan náà nínú fọ́tò 9 yẹn. A lè ka èyí náà kún ara agbè jíjá ṣùgbọ́n ìdí kan pàtàkì tí ó mú wa ya irúfẹ́ ijó yìí sọ̀tọ̀ ni pé fífí èjìká jó báyìí wọ́pọ̀ púpọ̀ ju irúfẹ́ agbè jíjá mìíràn lọ, àti pé nípa àmúlò fífi èjìká jágbè yìí ni àwọn onílù agbè fi máa ń bá ìwọ́hùn orin agbè lọ, tí wọn kò sì fi ní í ṣi agbè náà lù. Ẹ jẹ́ kí á wo àwòrán 10 fún àpẹẹrẹ fífi-èjìká jó nínú orin kete.



**Àwòrán 10:** Abọyẹ̀rì-kete ń fi èjìká jó lẹ́yìn tó parí ìyíkàá

Bí a bá wo àwòrán fọ́tò 10, a óò rí i pé Abọyẹ̀rì ṣì wà ní orí orókún/ eékún rẹ̀, ó yẹ èjìká ọ̀tún rẹ̀ sílẹ̀ nígbà tí ó ká ti apá òsì sókè. Gẹ́gẹ́ bí ìṣeré orin kete ti fi hàn, ọ̀nà láti jó bí àwọn obìnrin ṣe máa ń yúnra ni ó dàbí ẹni pé fífí-èjìká-jó nínú orin kete ń pa lárokò. Lára ohun tí ó mú wa rò bẹ́ẹ̀ ni pé bí ó tìlẹ̀ jẹ́ pé ọkùnrin ni Abọyẹ̀rì, ìmúra rẹ̀ bí i ti obìnrin ni. Obìnrin nìkan ní í máa sán yẹ̀rì, bàǹtẹ́ ni ọkùnrin máa ń san láyé àtijọ́. Nítorí náà ni kò ṣe yani lẹ́nu pé ìsínjẹ bí obìnrin ti ń jó ni Abọyẹ̀rì ń ṣe nípasẹ̀ fífi èjìká jó yẹn. Lọ́nà míràn ẹ̀wẹ̀, òrìṣà obìnrin ni Alárá-Igbó/ Ìyálóde tí wọ́n máa ń fi ìṣeré orin kete yẹ́ sí, wọn óò sì fẹ́ láti ṣe eré kí ó dára, kí ó sì tẹ́ ẹ lọ́rùn. Bí Abọyẹ̀rì bá ti lè ṣe é dáradára kí ó bá ti àwọn obìnrin, tí a gbà pé àwọn ni wọ́n mọ̀ ọ́n jo jù lọ mu tó sí ni a lérò pé ijó rẹ̀ yóò ṣe jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà sí. Fífi èjìká jó nínú ìṣeré orin agbè kì í ṣe ìsínjẹ tí ń tọ́ka sí bí obìrin ti ń jó rárá. Ní ti àwọn alagbè, wọ́n máa ń fi èjìká jó tẹ̀lé ìwọ́hùn orin agbè, kí wọ́n má baà ṣì agbè lù ni. Èjìká fífijó wá jẹ́ bí àmì alàgàta láàrin ìwọ́hùn orin àti agbè lílù. Èyí fi hàn wá gbangba wí pé àmì ìtọ́nisọ́nà ìṣewẹ́kú ìwọ́hùn orin àti ìwọ́hùn agbè ni fífí-èjíká-jó kọ́kọ́ jẹ́ nínú orin agbè. Kò sí àní-àní nínú pé ó tún jẹ́ àmì ìmọ́-ọ̀n-ṣe pọ́nńbélé nínú àwọn ìṣeré orin méjèèjì náà.

**Ijó àti ilù/agbè lílù papọ̀ lẹ́ẹ̀kan náà**

Kí onílù máa jó lásìkò tí ó ń lu ìlù tàbí ohun èlò ìṣeré mìíràn lọ́wọ́ wọ́pọ̀ nínú àwọn orin Yorùbá, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Yorùbá máa ń sọ pé, “Alubàtá kan kì í dárin.” Ijó ipá tí ijó bàtá jẹ́, èyí tí ó gba pé kí onílù rẹ̀ gbọ́dọ̀ fi gbogbo ọkàn sí ọ̀dọ̀ oníjó, pẹ̀lú ọwọ́ méjèèjì tí alùyá-ìlù bàtà fi máa ń lù ú ni a lérò pé ó fa irúfẹ́ òwe yìí. Ní ayé òde òní, a ti rí àwọn alùbàtá tí wọ́n máa ń dárin dáradára. Àpẹẹrẹ ni ti ọkùnrin oníbàtá kan tí a mọ̀ sí Kọ́lá Bàtá, ẹni tó le jó bàtá, kí ó lùlù bàtá, kí ó sì kọ orin ní àkókò ìṣeré kan ṣoṣo. Ìwádìí yìí fi hàn pé àwọn onílù kete àti àwọn alágbè le lu ìlù tàbí agbè, kí wọ́n jó, kí wọ́n sì tún kọrin nínú ìṣeré kan náà. Àwọn àwòrán onífọ́tò 11 àti 12 ìsàlẹ̀ yìí ṣe àfihàn ibi tí àwọn onílù kete àti alaagbè ti ń jó papọ̀ mọ́ ìlù àti agbè lílù.



**Àwòrán 11:** Oníyàá ìlù kete ká ẹsẹ̀ kan sókè nígbà tí ó ń jó bí ó ṣe ń lu ìlù

Nínú àwòrán 11 òkè yẹn, a rí oníyàá ìlù kete, tí ó ń lùlù fún àwọn olùsìn òrìṣà Alárá-Igbó, tí wọ́n wọ aṣọ funfun, tí wọ́n sì jókòó yẹn, bí ó ṣe ká ẹsẹ̀ kan sókè nígba tí ó ń jó, tí ó sì ń lu ìlù náà ní ẹ̀kọ̀ọ̀kan. Àmì ìfìmọ̀sílára ìgbádùn ìṣeré hàn ni a lérò pé èyí jẹ́. Ó sì tún jẹ́ àpẹẹrẹ ìmọ̀-ọ̀nṣe tó lóòrìn, èyí tí òṣèré náà ní. Kò sí ànì-àní pé bí òṣèré yìí ṣe ṣe náà fi í hàn gẹ́gẹ́ bí akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ tí ó dáńgájía nínú ìlù kete lílù. Bákan náà ni ọ̀rọ̀ ṣe rí pẹ̀lú oníyàá ìlù agbè tí a fi hàn nínú fọ́tò 12 ìsàlẹ̀ yìí:



**Àwòrán 12:** Oníyàá ìlù agbè gbé ẹsẹ̀ ọ̀tún sókè láti já agbè

Nínú àwòrán fọ́tò 12 òkè yẹn, ọkùnrin oníyàá ìlù agbè kan náà ni ó ń já agbè; bí ó ṣe ń lu agbè náà ni ó tún ń já a fúnra rẹ̀ nípa fífi ẹsẹ̀ ọ̀tún rẹ̀ tàpá . Èyí jẹ́ àmì ti ó fi hàn, bí akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ oníyàá-ìlù agbè tí ó péye. Nínú ìṣeré agbè, níbi tí a kò ti sín ìdò mọ́ ara agbè, ṣùgbọ́n tí ó jẹ́ pé ríro̩ ni a ro̩ ọ́ sí inú rẹ̀ ni àwọn tí ó ń lu agbè ti máa ń fi èjìká jó púpọ̀ jù lọ kí wọ́n le ní ìdánilójú bí àgbè tí àwọn ń lù náà ṣe ṣé é jó sí. Èyí tún jẹ́ àmì àrìdájú pé ìwọ́hùn ìró agbè náà ń ṣe wẹ́kú orin agbè. Ó yẹ kí á yán an pé ìró agbè tí a rọ ọmọ ìdò tàbí èso mìíràn sí kì í fi bẹ́ẹ̀ dún tó èyí tí a sín. Ìdí nìyí tí àwọn onílù agbè náà máa ń fi nílò láti máa fi èjìká jó láti ìbẹ̀rẹ̀ eré kí wọ́n lè rí í dájú pé ìṣewẹ́kú àárín ìwọ́hùn ìró agbè, tí wọ́n ń lù, kò tàsé ti orin àti ti ijó nínú ìṣeré wọn. Irúfẹ́ ijó báyìí jẹ́ àmì òdiwọ̀n ìṣewẹ́kú ìwọ́hùn ìṣeré orin agbè náà lápapọ̀.

**Olóbìírípobírí/ bírípo**

Olóbìírípobírí ni orúkọ ijó tí àwọn òṣèré ti máa ń tò yípo ara wọn láti pe ara wọn níjà nínú orin agbè. Bírípo ni wọ́n ń pe irúfẹ́ ijó tí ó fara pẹ́ ẹ nínú ìṣeré orin kete. O hàn gbangba pé orúkọ àwọn ijó méjèèjì yìí fi ara pẹ́ ara nípasẹ̀ ìrísí àwọn ìró ohùn àti ìhun wọn. Kò sí àní-àní pé láti inú “bírípo”, tí ó jẹ́ ọ̀rọ̀ oníhun kúkurú ni a ti ṣẹ̀dá ‘olóbìírípobírí’, tí ó jẹ́ ọ̀rọ̀ oníhun gígùn. A ṣẹ̀dá “bírípo” gan-an fúnra rẹ́ láti inú àkànpọ̀ “bírí” àti “po” (bírí + po = bírípo). Nígbà tí a wá so mọ́fíìmù aláfòmọ́ ìbẹ̀rẹ̀ asọdorúkọ ‘ò-’ mọ́ bírípo (ò- + bírípo), àyọrísí àsomọ́ náà jẹ́ ‘òbírípo.’ Nígbà tí a ṣe àwítúnwí ẹlẹ́bẹ fún ọ̀rọ̀ tuntun yìí ó di ‘òbírípobírí.’ Nígbà tí a tún wá fi mọ́fíìmù aláfòmọ́ asọdorúkọ ‘oní-’ kún ọ̀rọ̀ àbájáde yìí (oní + òbírípobírí) ni ọ̀rọ̀ náà di ‘ olóbìírípobírí.’ Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ àwòrán fọ́tò 13 ìsàlẹ̀ yìí níbi tí àwọn òṣèré orin agbè ti jó ijó olóbìírípobírí.



**Àwòrán 13:** Àwọn onílù orin agbè pín ara wọ́n sí ọ̀wọ́ méjì láti jó yípo agbo nínú ijó olóbìírípobírí

Orin “Olóbìírípobírí; Òní la ó malárẹ́” (Ògúndèjì 1979) ni àwọn òṣèré orin agbè máa ń kọ bí wọ́n bá ń jó ijó yìí lọ́wọ́. Orin yìí jẹ́ kí á mọ̀ pé níṣe ni àwọn òṣèré ń lo ijó olóbìíríbobírí láti fi pe ara wọn níjà fún ìṣeré tó wuyì. Kò sí àní-àní pé àmójúsùn ìpèníjà tí wọ́n ní náà ní ó sì jẹ́ kí wọ́n pín ara wọn sí ọ̀wọ́ afigagbága méjì, tí wọ́n sì ń kọrin pé “Òní

la ó maláré", (i.n.p. Òní ni a ó mọ ẹni tí ó mọ ijó jó jù lọ). Níorí náà, a lè sọ pé àmì ìpèníjà fún ìṣeré tó gbayì-gbẹ̀yẹ ni ijó yìí jẹ́ nínú ìṣeré orin agbè. Ẹ jẹ́ kí á wo fọ́tò 14 fún àpẹẹrẹ ijó bírípo nínú ìṣeré orin kete



**Àwòrán 14:** Abọ̀yẹ̀rì ń pòòyì rànhìn láti jó bírípo nínú ìṣeré orin kete

Nínú àwòrán 14 òkè yìí, abọ̀yẹ̀rì pòòyì rànhìn lójú kan náà bí ó ti ń jó nínú ìṣeré orin kete. Pípòòyì rànhìn yìí ni àwọn òṣèré orin kete pè ní bírípo tí wọ́n fi sọ orúkọ ijó yìí ní tiwọn. Pípòòyì náà ni ó mú yẹ̀rì rẹ̀ nà tí ó fí fẹ̀ dà bí abùradà tí ń yí, tí ẹwà rẹ̀ sì yọ. Bí a bá wo yẹ̀rì tí abọyẹ̀rì wọ̀ ní àsìkò tí ó ń pòòyì náà, a ó rí i pé àwọn awẹ́ tí a rán lórí ara wọn, èyí tí a fi aṣọ aláwọ̀ èsùrú gbá létí ṣí wẹ́lẹ́wẹ́lẹ́. Èyí sì ló jẹ́ kí á rí i bí yẹ̀rì náà ṣe fẹ̀ tó. Ó tún jẹ́ kí á rí i pé pípòòyì tí abọyẹ̀rì pòòyì náà pọ̀ tó bẹ́ẹ̀ tí a kò fi le rí ọnà tó wà lára yẹ̀rì náà gẹ́gẹ́ bíi ti ara búbá àwọ̀lékè oníjó náà, tí ó hàn kedere. Lásìkò ìṣeré ijó tí a fi àwòrán rẹ̀ hàn nínú fọ́tò 14 yìí, ìwọ́hùn ìlù ń sáré tete, kò sì sí ijó tí abọyẹ̀rì le jó tó le bá ìlù náà mu bíi yíyípo báyìí. Bí a bá wo ohun tí ó ṣẹlẹ̀ níbí, a lè sọ pé àmì ìṣewẹ́kú ìṣeré lápapọ̀ ni ijó yìí. Ó sì tún jẹ́ àmì àtọ́ka-sí ìmọ̀-ọ́n-ṣe tí ó múná dóko. Bí àfikún, a ti pe àkíyèsí sí i wí pé obìnrin ni ó máa ń sán yẹ̀rì ní ilẹ̀ Yorùbá, bí abọyẹ̀rì, tí ó jẹ́ ọkùnrin ṣe sán yẹ̀rì, tún le jẹ́ àmì ṣíṣe pàtàkì obìnrin nínú ìṣeré orin kete. A sì tún le rí yẹ̀rì sísán náà bí àmì atọ́ka sí Alárá-Igbó, òrìṣà obìrin tí a sọ pé wọ́n ń fi ìṣeré orin kete sọrí rẹ̀.

Ohun kan tí á kò gbọdọ̀ ṣaláì mẹ́nu bà ní ìhín ni ìjọra àti ìyàtọ̀ tí ó wà láàrín ijó bírípo nínú ìṣeré orin koto àti olóbìírípobírí nínú ìṣeré orin agbè. A ti yànnàná bí ó ṣe jẹ́ pé láti inú ọ̀rọ̀ orúkọ 'bírípo' tí a fi pe ijó inú ìṣeré orin kete ni a ti ṣẹ̀dá 'olóbìírípobírí' tí a fi pe ijó inú ìsere orin agbè. Èyí lè fẹ́ jẹ́ kí ènìyàn lérò pé irú ijó kan náà ni wọ́n. Gẹ́gẹ́ bí àlàyé wa ti fi hàn, ijó àdájó ni bírípo nińú ìṣeré orin kete; Abọyẹ̀rì nìkan ni ó dá ijó náà jó. Nínú ìṣeré orin agbè ẹ̀wẹ̀, àjùmọ̀-jó àwọn eléré púpọ̀ ni olóbìírípobírí. Bí a ṣe fi hàn nínú àlàyé wa ní òkè, àwọn alágbè pín ara wọn sí ọ̀wọ́ méjì, ọ̀wọ́ kọ̀ọ̀kan sì ń jó yípo agbo kékèké tí wọ́n pa lati fi agagbága. Àwọn ijó méjèèjì bára mu nípa ìgbésẹ̀ yíyípo, ṣùgbọ́n irú ìyípo ti ọ̀kan yàtọ̀ sí ti èkejì bí àlàyé wa ti fi hàn lókè yẹn. Àkíyèsí wa ni pé orúkọ tí wọ́n fi perí/ sàmì ọ̀kọ̀ọ̀kan ṣe régí ìṣeré kọ̀ọ̀kan. Orúkọ oníhun kúkurú (sílébù mẹ́ta) ni a fi perí/

sàmì ìṣeré ijó bírípo tí ó jẹ́ aládàá-jó, nígbà tí a lo orúkọ oníhun gígùn láti perí/ sàmì ìṣeré olóbìírípobírí (sílébù méje) tí ó jẹ́ alájùmọ̀-jó.

**Ijó tí í máa jẹyọ nínú ìṣeré orin kete nìkan ṣoṣo**

Oríṣi ijó kan tí ó máa ń jẹ yọ nínú ìṣeré orin kete tí kì í jẹ yọ nínú ìṣeré orin agbè, tí a óò jíròrò lé lórí ni ijó yíyatan-pípatandé.

**Ijó yíyatan-pípatandé**

Orí ìlóṣòó ni abọ̀yẹ̀rì ti máa ń jó ijó náà, tí yóò sì máa yatan rẹ̀, tí yóó máa pa á dé gẹ́lẹ́ bíi ìgbà tí obìnrin tó ya aṣa bá ń jó, tí ó ń fẹ abẹ́ rẹ̀ sí àwọn òǹwòran. Bí abọyẹ̀rì bá ti ń ṣe èyí, àwọn òǹwòran ó máa hó gèè, wọn yóò sì máa rẹ́rìn-ín nítorí bí ọ̀ṣèré yìí ṣe ń ṣe yìí. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ ijó yíyatan-pípatandé nínú fọ́tò 15 ìsàlẹ̀ yìí:



**Àwòrán 15:** Abọyẹ̀rì ń yatan, ó ń pa itan dé láti jó ijó yíyatan-pípatandé nínú ìṣere orin kete

Àwòrán onífọ́tò 15 fi Abọyẹ̀rì hàn ní ìlóṣòó, tí ó ya itan rẹ̀ sílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ìgbésẹ̀ kan nínú ijó yíyatan-pípatandé. Bí a bá kíyèsí i dáadá, a óò rí i pé Abọyẹ̀rì tún di bèbè ìdí. Ìlọ-sókè-lọ-sódò bèbè yìí ní àkókò ijó náà tún wà lára èròjà améré-dùn tí àwọn òǹwòran máa ń gbádùn dáradára. Orin kete a máa dá lorí kókó ọ̀rọ̀ ìbálòpọ̀ takọtabo púpọ̀. Ìdí nìyí tí ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ àwọn ọ̀dọ́mọkùnrin àti ọ̀dọ́mọbìnrin fi máa ń pọ̀ lára àwọn òǹwòran ìṣeré orin yìí. Àwọn òǹwòran wọ̀nyí máa ń nífẹ̀ẹ́ láti wo bí abọ̀yẹ̀rì ṣe ń rèdí, tí ó ń yatan, tí ó sì ń pa á dé. Àsìkò tí àwọn ọ̀kọrin bá ń kọrin ajẹmọ́bàálòpọ̀-takọtabo ni abọyẹ̀rì máa ń jó ijó yíyatan-pípatandé. Àpẹẹrẹ irú orin bẹ́ẹ̀ ni:

Règèrégè ré géńgé

Règèrégè ré géńgé

Ó di rè-gè-ré-gè-ré-géńgé

Kọ́kọ ó sùn lọ̀ọ̀dẹ̀

Káya ó sun yàrá

Bó bá di lálẹ́

Ṣe béèkù ó tọ̀bẹ

Règèrégè ré géńgé

Kò sí àní-àní pé ìbálòpọ̀ tákọ̀tábo ni kókó ọ̀rọ̀ tí àyọlò orin yìí dá lé bí a bá wo ìtumọ̀ àwọn ìpèdè inú rẹ̀ dáadaá. Bí a bá wo ìpèdè “règèrégè ré géńgé” tí wọ́n fl ṣíde orin náà, a óò ṣe àkíyèsí pé sílébù /ré/, àti /gé/ ni wọ́n fi dárà níbẹ̀. Bí a bá rí sílébù ré inú “.... ré géńgé....” bí ọ̀rọ̀ ìṣe tí a fà yọ látinú ‘rédìì’ tí a lè sọ pé ó túmọ̀ sí ṣíṣe ìbálòpọ̀ lákọlábo, a jẹ́ pé “....géńgé....” yóò jẹ́ ọ̀rọ̀ afìrógbóyeyọ àṣàpọ́nlé tí ó ṣàfihàn bí ìgbádùn ìbálòpọ̀ náà ti pọ̀ tó ni. Boyá a tilẹ̀ lè sọ pé ẹ̀dà ajémọ́nà ‘góńgó’, tí ó tùmọ̀ sí òtéńté tàbí góńgórí nǹkan náà ni ‘géńgé’ jẹ́. Àrànmọ́wájú afòròó ni a le sọ pé ó sọ /ó/ inú ‘góńgó’ di /é/ inú ‘géńgé’ ní ọ̀gangan ipò/ àyíká ọ̀rọ̀ ìṣe ‘ré’ inú àtòpọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ ìpèdè náà. Ohun tí ó dájú ni pé ìjẹ́mọ́nà ni ó darí ìṣàmúlò náà. Ìgbádùn tí ó dópin gan-an náà ni ìfọ̀rọ̀dárà afìrógbóyeyọ “règèrégè” ìbẹ̀rẹ̀ ìpèdè náà sì tún túmọ̀ sí, bí a bá wò ó dáradára. Irú ọ̀rọ̀ yìí ni Rifatterre (1978) pè ní ọ̀rọ̀ aláìnítumọ̀; ìyẹn ni pé kò dá ní ìtumọ̀ ara rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹyọ ọ̀rọ̀. Àpapọ̀ àwọn ìró inú rẹ̀, tí wọ́n jẹ́ onírú ìrísí kan náà pẹ̀lú àwọn ìró yòókù ní ọ̀gagan-ipò ìṣàmúlò rẹ̀ ni a fi fún un ni ìtumọ̀. (O yẹ kí á kíyèsí pé irú ọ̀rọ̀ kan náà ni ọ̀rọ̀ yìí pẹ̀lú ‘géńgé’ tí a ti ṣàlàyé lé lórí lókè).

Àwọn ìpedè yòókù inú orin náà túbọ̀ fẹ́sẹ̀ àtúplẹ̀ wa múlẹ̀ danindanin ni. Àwòrán tí àwọn olórin fi àwọn ìpèdè orin yòókù náà yà ni ti ọkọ ìyàwó tí ó kọ́kọ́ lọ nájú ní ẹ̀ẹ̀dẹ̀, bóyá lati gba atẹ̀gùn, ṣùgbọ̀n lẹ́yìnọ̀rẹyìn, nígbà tí ó yá, ó wọ́lé tọ aya rẹ̀, tí ó ti sùn sí yára tẹ́lẹ̀ lọ. Níwọ̀n ìgbà tí ó jẹ́ pé “eléèkù ni ó ni ọ̀bẹ”, bí àwọn àgbà Yorùbá tí í máa pa á lówe, kò yani lẹ́nu pé wọn jọ ní ìbálòpọ̀ lọ́kọláya, tí a tún máa ń dà pè ní “jíjẹ ẹran adùn-má-dẹ̀ẹ̀kẹ́”. Adùn yìí ni a lérò pé àwọn olórin náà fi ìpèdè “Règèrégè ré géńgé” ṣàpèjúwe. Níwọ̀n ìgbà tí ó jẹ́ pé àsìkò tí abọ̀yẹ̀rì ń jó ijó yíyatan-pípatandé ni orin yìí wáyé, kò sí àní-àní pé àmì ìbálòpọ̀ takọ̀tabo ni ijó yíyatan-pípatandé túmọ̀ sí nínú ìṣeré orin kete nígbà náà.

**Àwọn ijó tí í máa á jẹyọ nínú orin agbè nìkan**

Àwọn ijó tó máa ń jẹyọ nínú orin agbè ṣùgbọ́n tí kì í jẹyọ nínú orin kete tí a máa ṣàlàyé lé lórí nîìsinsinyí, gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe sọ ṣíwájú, ni ijó fiwájújó-fẹ̀yìnjó, yọpáyọsẹ̀/ ẹlẹ́yọ-ẹ̀yọ, fò-lálá àti mẹ́tamẹ́ta-ẹ̀là/ là-á-mẹ́ta.

**Fiwájújó-fẹ̀yìnjó**

Ijó fiwájújó-fẹ̀yìnjó jẹ́ oríṣi ijó agbè kan tí ó wọ́pọ̀ jùlọ láàárín àwọn ajóṣàkàrá ìlú Igbó-Ọrà. Àwọn ẹgbẹ́ ajóṣàkàrá yìí tilẹ̀ máa ń tọ́ka sí ara wọn nínú oríkì wọn gẹ́gẹ́ bí “Ọmọ Afẹ̀yìnjágbèwọjà.” Láti jó irúfẹ́ ijó yìí, àwọn onílù agbè a máa tò ní ìlà méjì, wọn yóò sì da ojú kọ ara wọn. Àwọn ọ̀wọ́ tí ó bá kẹ̀yìn da òpópó ibi tí wọ́n bá fẹ́ bá lọ ni yóò kọ́kọ́ máa fi ẹ̀yìn rìn lọ láì bojú wẹ̀yìn, àwọn tó dojú kọ wọ́n yóò sì máa rìn tọ̀ wọ́n. Oníjó agbè yóò wà ní iwájú àwọn tó ń fẹ̀yìn rìn yìí tí yóò máa já agbè kíkankíkan. Bí àwọn onílù agbè tó ń fẹ̀yìn rìn lọ yìí bá ti dé òpin ọ̀nà tàbí ibi tí kò ti sí àyè mọ́ lati tẹ̀ síwájú, wọ́n á dúró, àwọn tó ti dojú kọ wọ́n náà a sì bẹ̀rẹ̀ láti máa fi ẹ̀yìn rìn títí tí àwọn náà yóò fi dé ibi tí ijó ti bẹ̀rẹ̀ tàbí ibi tí kò ti sáyè mọ́. Oníjó agbè náà máa wà níwájú wọn, tí yóò sì máa jó. Àkíyèsí wa ni pé agbè máa ń sùn, èyí tó túmọ̀ sí pé àwọn onílù agbè máa ń lù ú kárakára ní àsìkò yìí ju ìgbà tí wọn kò fi ẹ̀yìn rìn lọ. Ó tún yẹ kí á yán an pé bí àwọn onílù agbè ṣe ń fẹ̀yìn rìn yìí náà ni wọn yóó máa fèjìká jó kárakára. Èyí wá já sí pé ohun tí àwọn onílù agbè ń ṣe papọ̀ lẹ́ẹ̀kan náà lásìkò yìí pọ̀ díẹ̀: wọ́n ń lu agbè, wọ́n ń fẹ̀yìn rìn, wọ́n sì tún ń jó. A le lo àwòrán onígi 1 ìsàlẹ̀ yìí láti fi ojú agbo ijó fíwájújó-fẹ̀yìnjó hàn.



↓

A 2 ↓ ↓ ↓ ↓ ↓ ↓ ↓ ↓ ↓

1 ↑ ↑ ↑ ↑ ↑ ↑ ↑ ↑ ↑

↓ ↓ **Ijó àjólọsíwájú**

↑ ↑

B 2 ↓ ↓ ↓ ↓ ↓ ↓ ↓ ↓ ↓

1 ↑ ↑ ↑ ↑ ↑ ↑ ↑ ↑ ↑ **Ijó àjólọsẹ́yìn**

**Àwọn òǹwòran**

**Àwòrán onígi 1: Ìrísí ojú-agbo ìṣeré ijó fíwájújó-fẹ̀yìnjó**

Àwọn ọfà kékèké tí a yà wọ̀nyẹn dúró fún ọ̀wọ́ onílù, tí a pè ní A1, A2 àti B1, B2. Àwọn tó wà lórí ìlà A1 ni ó máa kọ́kọ́ bẹ̀rẹ̀ sí ní í fẹ̀yìn rìn, tí àwọn tó wà ní orí ìlà A2 yóò sì máa rìn tọ̀ wọn bí wọ́n ṣedojúkọ wọ́n náà. Àwọn ọfà tó wà ní àárín yẹn ni oníjó, wọ́n le tó méjì tàbí mẹ́ta. Nígbà tí ijó náà dé ibi tí ó lápẹẹrẹ, àwọn oníjó orí ìlà B1 tó ti jẹ́ A1 tẹ́lẹ̀ dúró, àwọn oníjó orí ìlà B2 tó ti jẹ́ A2 tẹ́lẹ̀ gba fífí ẹ̀yìn rìn jó náà, àwọn oníjó orí ìlà B1 tó jẹ́ A1 tẹ́lẹ̀ á sí máa rìn tọ̀ wọ́n ní ìdojukọra bẹ́ẹ̀. Ẹ jẹ́ kí á wo àwòrán onífọ́tò 16 ìsàlẹ̀ yìí láti fi àpẹẹrẹ ijó fiwájújó-fẹ̀yìnjó hàn:



**Àwòrán 16:** Àwọn onílù agbè tò, kọjú sí ara wọn láti jó ijó fiwájújó-fẹ̀yìnjó

Bí àwọn ajóṣàkàrá/ alágbè/ ajágbè bá ń jó ijó fiwájújó-fẹ̀yìnjó lọ́wọ́, wọ́n máa ń kọ orin ìsàlẹ̀ yìí láti fi ki ara wọn:

Lílé: Bẹ bá fiwájú jo tán

Ẹ tún fẹ̀yìn jó

Gbígbè: Kòkòrò lọmọ Ajóṣàkàrá ó

Lílé: Bẹ bá fiwájú jo tán

Ẹ tún fẹ̀yìn jó

Gbígbè:: Kòkòrò lọmọ Ajóṣàkàrá ó

Orin yìí fi orúkọ ijó náà hàn. Nínú orin fíwájújó-fẹ̀yìnjó tí a tọ́ka sí yìí, a pè àwọn ọmọ Ajóṣàkàrá ní kòkòrò. Ìdí tí a fi pè wọ́n ní kòkòrò ni pé wọ́n mọ̀ ọ́n jó. Yorùbá máa ń pe ẹni tó bá mọ ijó jó dáradára ní kòkòrò. Ìdí ni pé Yorùbá máa ń fi títawọ́ àti títasẹ̀ pọ́n-ún-pọ́n-ún kòkòrò léraléra wé bí ènìyàn tó mọ ẹ̀wọ́n ijó ṣe máa ń tawọ́tasẹ̀ nínú ijó. Torí náà, níṣe ni a fi ènìyàn wé kòkòrò nínú ìpèdè ègbè orin náà. Kòkòrò gẹ́gẹ́ bí a ṣe lò ó nínú orin yìí jẹ́ àmì ìmọ̀-ọ́n-ṣe nínú ijó jíjó láwùjọ Yorùbá. Ẹ̀wẹ̀, bí a bá tún tọpa orin agbè lọ sí inú ìtàn ìpílẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí orin ogun, àmì ète ogun jíjà níbi tí jagunjagun kan ti ń ṣọ́/ dè ẹ̀yìn jagunjagun mìíràn tí ó ń ṣọ́ tirẹ̀ náà ni dídojúkọra-ẹni nínú eré orin agbè yìí dúró fún. A lè sọ pé ijó náà jẹ́ àmì fún ọgbọ́n ìṣètò lójú ogun, èyí tí àwọn ajágbè ń tọ́ka sí láti mú wá sí ìrántí nínú ìṣeré wọn.

**Yọpáyọsẹ̀/ ẹlẹ́yọ-ẹ̀yọ**

Ijó yọpáyọsẹ̀ ni ijó kan tí ó máa ń wáyé nínú orin agbè níbi tí ajágbè ti ń já àgbè nígbà tí ó bá na ẹsẹ̀ rẹ̀ ọ̀tún sí ibi tí ó na apá rẹ̀ òsì sí. Èyí a wá jẹ́ pé níṣe ni ó ń na apá àti ẹsẹ̀ rẹ̀ náà ní ìpẹ̀sípẹyọ. Ẹ̀wẹ̀, oríṣi ijó yìí mìíràn ni èyí tí ó máa ń wáyé nígbà tí ajágbè bá na apá àti ẹsẹ̀ rẹ̀ sí ibi kan náà. Èyí túmọ̀ sí pé ibi tí ó bá na apá rẹ̀ sí náà ni yó na ẹsẹ̀ rẹ̀ sí. A rí ajágbè tó ní ìmọ̀-ọ́n-ṣe nínú oríṣi ijó méjèèjì náà. Bí àwọn ajágbè ìlú Ilùà, ní Òkè-Ògùn, Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́ bá ń jó ijó yìí, orin tí wọ́n sábàá máa ń kọ nìyí:

Lílé: Ó dẹlẹ́yọ-ẹ̀yọ
Ẹ̀yọ màrìwò ò
Gbígbè: Ẹ̀yọ-ẹ̀yọ
Ẹ̀yọ màrìwò
Lílé: Bọ́gàn bá yọ nígbó
Mo ṣe bí í ta wọn yọ
Gbígbè: Ẹ̀yọ-ẹ̀yọ
Ẹ̀yọ màrìwò
Lílé: Ẹgbẹ́ mi bá wọn
Yọ́ọ̀ ta wọ́n yọ
Gbígbè: Ẹ̀yọ-ẹ̀yọ
Ẹ̀yọ màrìwò

Orin òkè yìí jẹ́ ọ̀kan lára àwọn orin tí àwọn alágbè máa ń kọ láti fi wúre fún ara wọn. Èyí sì hàn gbangba nínú gbólóhùn àwíṣẹ oníhun ká-ní ibẹ̀, àti ti iṣẹ́ tí wọ́n fẹ́ fi ọfọ̀ inú orin náà jẹ́. “Bọ́gàn bá yọ nígbó; Mo ṣe bí í ta wọn yọ: Ẹgbẹ́ mi bá wọn; Yọ́ọ̀ ta wọ́n yọ.” Àwọn ọ̀kọrin agbè fi orin yìí wúre fún ẹgbẹ́ òṣèré wọn kí wọ́n le borí nínú ìdíje ìṣeré pẹ̀lú ẹgbẹ́ eléré ìbílẹ̀ mìíràn ni. “Ẹ̀yọ-ẹ̀yọ; Ẹ̀yọ màrìwò” tí wọ́n lò bí ègbè orin náà ń tọ́ka sí ewé ọ̀dọ́mọ̀/ ọ̀gọ́mọ̀ tí ó máa ń yọ ṣooro lórí igi ọ̀pẹ. Èyí a sì máa mú ọ̀pẹ ga ju gbogbo igi tó wà ní àyíká rẹ̀ lọ.

Bákan náà ni a le sọ nípa “ọ̀gàn” (i. n. p. ilé ikán) tí a tọ́ka sí nínú orin yìí. Òkìtì ọ̀gàn a máa yọ daradara ju àwọn ewéko àyíkà rẹ̀ lọ ní ilẹ̀ ọ̀dàn. Èyí ni àbùdá rẹ̀ tí àwọn ọ̀kọrin níláti ní lọ́kàn tí wọ́n fi lò ó gẹ́gẹ́ bí àmì àfidipò ara wọn nínú ọfọ̀ ìwúre ìtayọ-ẹgbẹ́ ẹni náà. Bí èyí bá rí bẹ́ẹ̀, a jẹ́ pé ìfọ̀rọ̀dárà alárokò títa-ẹgbẹ́-ẹni-yọ ni ìpèdè “Ẹ̀yọ-ẹ̀yọ; Ẹ̀yọ màrìwò” yẹn jẹ́, ní pàtàkì jùlọ bí ó ṣe jẹ yọ pọ̀ pẹ̀lú ọ́rọ̀ ìṣe “yọ” nínú orin náà. Apẹẹrẹ ijó ẹlẹ́yọ-ẹ̀yọ/ yọpáyọsẹ̀ fara hàn nínú fọ́tò 4 tí a ti tọ́ka sí ṣaájú. A lo àwòrán onífọ́tò náà láti ṣe àpẹẹrẹ agbè jíjá tẹ̀lẹ̀ ni. Ohun tí ó ṣẹlẹ̀ ní pé nígbà tí oníjó náà ń jó ijó ẹlẹ̀yọ-ẹ̀yọ ni ó já agbè. Nínú fọ́tò 4 náà, a kíyèsí i pé apá àti ẹsẹ̀ òsì ni ọkùnrin onijó agbè náà nà síwájú papọ̀.




**Àworán 17:** Akitiyan oníjó láti jó ijó yọpáyọsẹ̀/ẹlẹ̀yọ-ẹ̀yọ

Ó yẹ kí á tún yán an pé ijó ẹlẹ́yọ-ẹ̀yọ/ yọpáyọsẹ̀ tí ajágbè jó nínú àwòrán 17 tún yàtọ̀ díẹ̀ sí ti inú àwòrán 4 nítorí pé ti àwòrán 17 yẹn mú ipá díẹ̀ lọ́wọ́. Pẹ̀ǹpẹ̀kun ni ajágbè ń já nínú ijó àwòrán 17 kì í ṣe ìyá agbè bíi ti ajágbè inú àwòrán 4. Láti já pẹ̀ǹpẹ̀kun nínú ijó yọpáyọsẹ̀/ ẹlẹ́yọ-ẹ̀yọ gẹ́gẹ́ bí ajágbè ṣe já a nínú àwòrán 17 yìí nílò ìyára kánkán àti ipá, kí oníjó le tẹ̀lé ìwọ́hùn ìró agbè bí ó ṣe tọ́ àti bí ó ṣe yẹ. Àmi ijó líle àti eré ipá tí ijó agbè jẹ́ ni irú ìjó yọpáyọsẹ̀ bẹ́ẹ̀ dúró fún nínú orin agbè. Ó sì tún dúró bí àmì ìṣewẹ́kú pẹ̀lú ìwọ́hùn ìró agbè lásìkò ìṣeré.

**Ijó Fò-lálá**

Ijó fò-lálá jẹ́ ọ̀kan nínú ijó ipá tí ó máa ń jẹ yọ nínú ìṣeré orin agbè nígbà tí a bá ń kọrin pé kí oníjó agbè fò sókè láláálá láti jó sí orin agbè. A tilẹ̀ máa ń fi ijó yìí pe àwọn ajágbè níjà ni kí á le mọ bí ajágbè kan ṣe ní ìmọ̀-ọ́n-ṣe tó nínú irúfẹ́ ijó náà. Láti jó ijó fò-lálá, bí ajágbè bá ti ń jó ni yóó máa fò sókè láláálá ní ẹ̀ẹ̀kọ̀ọ̀kan tí a bá ti fi orin pè é níjà pé kí ó fò sókè lálá. Àpẹẹrẹ ijó fò-lálá hàn nínú àwòrán 18 ìsàlẹ̀ yìí:



**Àwòrán 18:** Àwọn obìnrin oníjó agbè wọ̀nyí fò sókè láti jó ijó fò-lálá

Bí a bá wo àwòrán 18 yìí, a ó rí i wí pé àwọn obìnrin méjèèjì wọ́n dojú kọra káwọ́ sókè nígbà tí wọ́n ń fò sókè bí wọ́n ti ń jó ijó fò-lálá ni. Ìpèníjà láti mọ bí ara oníjó ṣe dáńgájíá sí ni ijó fò-lálá ń tọ́ka sí nínú ìṣeré orin agbè, nítorí náà, àwọn ọ̀dọ́mọdé tí eegun wọ́n le dáradára ni ó máa ń jó o. Torí pé obìnrin tó kọjú sí èkejì rẹ̀, tó dé fìlà aláwọ̀ èsúrú nínú àwòrán 18 náà kò lómi lára ni ó ṣe ní àǹfààní láti fò sókè dáradára ju èkejì, tí ó dé fìlà náà, tí ó sì kẹ̀yìn sí ayafọ́tò lọ. Àmì láti fi hàn bí ara ẹni ṣe fẹ́rẹ̀ tó ni ijó fò-lálá jẹ́.

**Mẹ́taméta-ẹ̀là/ là-á-mẹ́ta**

Gẹ́gẹ́ bí ìwádìí wa ṣe fi hàn, ijó agbè tí ó lágbára jùlọ, tí kò sí ẹni tó le jó o mọ́, bí kò ṣe àwọn tí wọ́n kàn le gbìyànjú rẹ̀ lásán ni ijó mẹ́taméta-ẹ̀là/ là-á-mẹ́ta. Ijó yìí jẹ́ ijó tó jẹ́ pé ó nílò àmúlò ipá àti agbára òògùn. Láti jó ijó mẹ́taméta-ẹ̀là/ là-á-mẹ́ta, ojú kan ṣoṣo ni àwọn oníjó máa ń dúró sí, wọ́n le máa gbé ẹsẹ̀ sókè, kí wọ́n sì máa fi janlẹ̀ tàbí kí wọ́n máa fi iwájú ẹsẹ̀ tàbí gìgísẹ̀ túlẹ̀ tí orí ilẹ̀ tí wọ́n dúró sí náà yóò sì di èyí tí wọ́n ti fi ẹsẹ̀ fọ́. Àlagbà Tìámíyù Òjó tí ó jẹ́ aṣojú Baálé ilé Ajóṣàkàrá Igbó-Ọrà jẹ́wọ́ fún wa lásìkò ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò tí a ṣe fún wọn ní ọjọ́ kejìlélógún, oṣù keje, ọdún okòó-lé-lẹ́gbàá-dín-méjì (22/ 7/ 2018) pé àwọn ajágbè ayé àtijọ́ gẹ́gẹ́ bíi Láǹgabà kì í jó ijó yìí lásán. Wọ́n máa ń lo òògùn láti fi jó ijó àgbàyanu náà ni. Àpẹẹrẹ ìgbìyànjú ijó mẹ́taméta-ẹ̀là/ là-á-mẹ́ta ni a fi hàn nínú àwòrán 19 àti 20 ìsàlẹ̀ yí:



**Àwòrán 19:** Oníjó agbè kìn-ín-ní tí ó fi aṣọ funfun kọ́rùn àti èkejì tó wọ ṣapará ń gbíyànjú láti jó ijó mẹ́taméta-ẹ̀là

Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ, ìgbìyànjú lásán ni èyí; àwọn oníjó méjèèjì inú àwòrán 19 jó nítòótọ́, ní pàtàkì jùlọ, ajágbè kejì tí ó wọ ṣapará yẹn, ṣùgbọ́n wọn kò le fi ẹsẹ̀ wọn fọ́ ilẹ̀ gẹ́gẹ́ bí Láǹgabà ti máa á ṣe ní ayé àtijọ nígbà tí ó bá ń jó ijó náà.



**Àwòrán 20:** Ajágbè fi igórí ẹsẹ̀ tilẹ̀, ó sì gbìyànjú láti jó ijó mẹ́taméta-ẹ̀là

A ti ṣe àlàyé pé òṣèré agbè tí àwọn ajágbè kà sí ọ̀gá oníjó agbè ni ó máa ń jó ijó mẹ́taméta-ẹ̀là. Bí ajágbè bá ṣe le jó ijó yìí tó ni àwọn òṣèré orin agbè yóó ṣe gbà á ní ọ̀gá oníjó sí. Nítorí ìdí èyí, àmì òpin ijó agbè, gẹ́gẹ́ bí gẹ̀lẹ̀dẹ́ ṣe jẹ́ òpin ìran, tí idán ìyàwó jẹ́ òpin idán egúngún aláré ni ijó mẹ́taméta-ẹ̀là jẹ́ òpin/ òtẹ́ńté ijó orin agbè.

**Àgbálọgbábọ̀**

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe ṣe àlàyé nínú àpilẹ̀kọ yìí, orin kete àti orin agbè jọra nípasẹ̀ ìṣẹ̀dá orúkọ wọn àti nítorí pé ohun èlò orin wọn tí ó gbajúmọ̀ jùlọ ni a fi sọ wọ́n lórúkọ. Bákan náà ni a tọ́ka sí i pé lára oríṣi irúgbìn kan náà (akèrègbè) ni a ti yọ àwọn ohun èlò orin méjèèjì wọ́nyí. Yorùbá máa ń pa á lówe pé ìtàkùn tó so igbá, ló so agbè, tó sì so elégédé. A fi hàn pé kete tí a fi sọ orin kete lórúkọ jẹ́ èyí tí a mú jáde láti ara agbè. A jẹ́ kí ó yé wa pé agbè kete ní tirẹ̀ kì í ni ọrùn gẹ́gẹ́ bí agbè tí a fi ṣe ohun èlò orin agbè ti máa ń ní ọrùn. A ṣe àlàyé pé níṣe ni a máa ń sín àwọn èso bíi ìdò mọ́ agbè lára tàbí kí á dà á sí inú rẹ̀ láti ṣe ohun èlò orin agbè.

A ní a máa ń se awọ sí ojú kete ni láti ṣe ìlù kete. A fi kún àlàyé wa pé orin ìjọsin àti ìdárayá/ ayẹyẹ ni orin kete, ṣùgbọ́n bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé orin ogun ni orin agbè ní àtijọ, ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ rẹ̀, orin ìdáráyá/ ayẹyẹ pọ́ńńbélé ni ní òde òní. Gẹ́gẹ́ bí a ti fi hàn nínú àpilẹ̀kọ yìí, kì í ṣe nípa orúkọ nìkan ni àwọn ìṣeré orín méjèèjì yìí fi jọra, wọ́n jọra nípa àwọn ijó kan. Àwọn ijó tí a sọ pé wọ́n máa ń wáyé níbi ìṣeré àwọn orin méjèèjì, tí wọ́n fi jọra ni ìlù/ agbè jíjá, ìdòbálẹ̀/ ìyíkàá, fífi-èjìká-jó, ijó jíjó àti ilù/ agbè lílù papọ̀ lẹ́ẹ̀kan náà pẹ̀lú olóbìírípobírí/ bírípo. Ijó yíyatan-pípatandé nìkan ni a sọ pé ó máa ń jẹ yọ nínú ìṣeré orin kete ṣùgbọ́n tí kì í jẹ yọ nínú ti orin agbè. Àwọn ijó tí a ní wọ́n máa ń jẹ yọ nínú orin agbè ṣùgbọ́n tí kì í jẹ yọ nínú orin kete ni fífiwájújó-fẹ̀yìnjó, yọpáyọsẹ̀/ ẹléyọ-ẹ̀yọ, fò-lálá àti mẹ́taméta-ẹ̀là/ là-á-mẹ́ta.

A rí i pé àwọn àmì tó jẹ mọ́ ẹ̀sìn ìbílẹ̀ Yorùbá hàn nínú ijó orin kete. Èyí kò yani lẹ́nu nítorí gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe àlayé, eré orin tí ó wà fún ìjọ́sìn òrìṣà Alárá-Igbó ni orin kete. Àpẹẹrẹ irú ijó bẹ́ẹ̀ ni ìyíkàá tó jẹ́ àmì ìbọ̀wọ̀-fún àti ìjúbà òrìṣà Alárá-Igbó àti àmì ojú-ẹgbẹ́, tí ó dúró fún ojúbọ òrìṣà Alárá-Igbó. Àwọn àmì ajẹmáṣà ìbágbépọ̀ láwùjọ ni a lè pe àwọn àmì inú ìṣeré ijó orin agbè. Àpẹẹrẹ ni ìdọ̀bálẹ̀ tó jẹ mọ́ àṣà ìkíni àti fífi ẹ̀yìn rìn tó jẹ mọ́ ọgbọ́n ìṣètò ogun jíjà. Àrokò ìmọ̀-ọ́n-ṣe nínú ijó jíjó wọ́pọ̀ nínú orin méjèèjì ṣùgbọ́n èyí wọ́pọ̀ nínú orin agbè ju orin kete lọ.

Àwọn ijó tí wọn jẹ́ àmìtọ́ka sí ìṣewẹ́kú náà wà nínú ìṣeré àwọn orin méjèèjì dáradára. A ṣe àkíyèsí pé a rí ijó bíi bíripo tí ó jẹ mọ́ ìlò ipá nínú ìṣeré orin kete, ṣùgbọ́n inú ìṣeré orin agbè ni irú ijó bẹ́ẹ̀ pinmirin sí nítorí pé ṣàṣà ni ijó tí kò jẹ mọ́ ipá nínú ìṣeré orin agbè. Kò sí òṣèré tí kò le jó nínú àgbékalẹ̀ ìṣeré orin méjèèjì ṣùgbọ́n yàtọ̀ sí olórí oníjó (b. a. Ìyàwó Agbè/ Abọyẹ̀rì), àwọn òṣèré yòókù máa ń jó nínú ìṣeré orin agbè ju bí wọ́n ṣe máa ń jó nínú ti orin kete lọ. Àpẹẹrẹ èyí ni tí àwọn onílù agbè tí ó máa ń jó láti bá ìwọ́hùn orin dọ́gba. Ó hàn kederé pé àmì ẹ̀sìn Alárá-Igbó máa ń jẹ yọ púpọ̀ nínú àwọn ijó orin kete nígbà tí àpẹẹrẹ ìmọ̀-ọ́nṣe pọ́ńńbélé àti bí òṣèré ṣe lágbára tó máa ń jẹ yọ nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ijó orin agbè. í àkótán, kò sí àní-àní wí pé àmì ìméré-dùn ni àwọn ijó wọ̀nyí, bẹ́ẹ̀ sì ni àpapọ̀ wọn pẹ̀lú orin a máa jẹ́ kí òye arokò tí wọ́n bá fi ijó náà pa túbọ̀ yéni sí i yéké yéké. Èyí a sí máa tún jẹ́ kí òǹwòran gbádùn ìṣeré àwọn orin náà dé góńgó.

## Lwé Ìtọ́kasí

Adélékè, D. A. (KND). *Ìfáárà sí orin àpilẹ̀kọ Yorùbá.* Ìbàdàn: Distance Learning Centre.
Àlàbá I. O. (1985). A Socio-Stylistic Analysis of *Orin Agbè*: A Multimodal Genre of Yorùbá Oral Poetry, àpilẹ̀kọ fún oyè Ph.D, Department of African Languages and Literatures, Faculty of Arts, University of Lagos.
Auslander, P. (2008). *Theory for Performance Studies*: *A Student's Guide*. New York: Routledge.
Cobley, P. (2005). *The Routledge Companion to Semiotics and Linguistics.* London: Routledge.
Eco, U. (1976). *A Theory of Semiotics.* U.S.A: Indiana University Press.
Jakobson, R. (1960). Closing Statement: Linguistics and Poetics, nínú *Style in Language*, ed. ``Thomas A. Sebeok, M. I. T., Massaachusets, Cambridge, o. i. 350-449.
Kíaríbẹ̀ẹ́, L. A. (2022a). Social Status of *Agbè* and *Kete:* A Historical and Functional Yorùbá Oral Literary Perspectives, nínú *Notion: Journal of Linguistics, Literature and Culture*, *vol. 4(2*), o.i. 76-84.
___________ (2022b). Àgbéyẹ̀wò Pípe Àkíyèsí Àwùjọ sí Ìlera wọn gẹ́gẹ́ bí ó ṣe máa ń Jẹyọ nínú Orin Ìbejì àti Orin Ẹgbẹ́, *Yorùbá: Journal of Yorùbá Studies Association of Nigeria*, *Vol. 10. No. 2*, o.i. 41-54.
__________(2023). A comparative performance semiotics of Orin Kete and Orin Agbè Among the Ìbàràpá and Òkè-Ògùn people of Yorùbá, Nigeria, àpilẹ̀kọ fún òyè Ph.D, Department of Linguistics and African Languages, Univerisity of Ibadan.
Lotman, Y. M. (1990). *The Universe of Mind: A Semiotic of Culture*. Bloomington and Indianapolis: Indiana University Press.
Ògúndèjì, P. A. (1979). Ṣàkàrá Song in Ìṣẹmilé, àpilẹ̀kọ fún oyè B.A., Department of Linguistics and African Languages, University of Ìbàdàn, Ìbàdàn.
__________ (1988). A Semiotic Study of Duro Ladipọ's Mythico-Historical Plays, àpilẹ̀kọ fún oyè Ph.D, Department of Linguistics and African Languages, University of Ibadan, Nigeria.
_________ (1991). *Introduction to Yorùbá Oral Literature*. Ibadan: University of Ibadan Centre for External Studies
________ 2000. *Ritual as Theatre, Theatre as Ritual: The Nigeria Example.* Ibadan: Ìbàdàn Culture Studies Group and Atlantic Books.
Òjó, M.A. (1978). Sákárà Muisic, àpilẹ̀kọ fún oyè M.A., Ẹka-ẹ̀kọ́ Ìmọ̀ ẹ̀dé-èdè àti èdè ilẹ̀ Adúláwọ̀, Yunifásitì Ìbàdàn.
Ọlátẹ́jú, M. O. A. (1998). A Syntactic Approach to Literary Discourse Analysis: The Yorùbá Example, àpilẹ̀kọ fún oyè Ph.D, Department of Linguistics and African Languages, University of Ibadan, Ibadan.
Ọ̀pádọ̀tun, Ọ. (2002). *Okòó ewì alohùn*. Ọ̀yọ́: Odumat Press & Publishers.
Owólabí, O. (1974). *Orí Adé Kìí Sùnta*. Lagos: Macmillan Nigeria Publishers Ltd.
Riffaterre, M. (1978). *Semiotics of Poetry*.Bloominngton àti London, Indiana University Press.
Schechner, R. (2004). *Performance Theory (Revised and Expanded Edition)*. New York and London; Routledge.
Sonnentag, S. and Frese, M. 2002. Performance Concepts and Performance Theory, nínú *Psychological Management of Individual Performance*, Sonnentag, S. ed., o.i. 4-25.

Recebido em: 23/02/2025
Aceito em: 24/06/2025

**Para citar este texto (ABNT):** KÍARÍBẸ̀Ẹ́, Luqman Abísọ̀lá; ÒGÚNDÈJÌ, Philip Adédọ̀tun. Àgbéyẹ̀wò oríṣiríṣi Ijó nínú Ìṣeré Orin Kete àti Orin Agbè. *Njinga & Sepé:* Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras. São Francisco do Conde (BA), vol.5, nº Especial I, p. 32-60, jan./jun.2025.

**Para citar este texto (APA):** Kíaríbẹ̀ẹ́, Luqman Abísọ̀lá; Ògúndèjì, Philip Adédọ̀tun. (jan./jun.2025). Àgbéyẹ̀wò oríṣiríṣi Ijó nínú Ìṣeré Orin Kete àti Orin Agbè. *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras.* São Francisco do Conde (BA), 5 (Especial I): 32-60.